# Ki ni Ifanimọra Ni Ori Oke Naa?

Jeffersonville, Indiana USA
Ọjọ Karundọgbọn Osu Keje, 1965

1 Ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba bayii. Baba wa Ọlọrun, eyiyi ni adura wa tọkantọkan ni alẹ yii, bi a se n ri ohun gbogbo ti Iwọ n se fun awọn eniyan ọjọ oni. Nigba naa awa beere lọwọ Rẹ, Oluwa, jẹ ki a saa gbagbọ pe Otitọ ni Ọrọ ti a kọ silẹ naa, ti a nsọ di arigbamu fun wa. Se eyi fun wa, Ọlọrun.

Bayii, ni alẹ yii, a fẹ dupẹ lọwọ Rẹ fun oye ti O fun wa nipa Iwe Mimọ ni owurọ yi. A si gbadura pe ki Iwọ ki O jẹrigbe Ọrọ Rẹ pe Otitọ ni, nigba ti a ba n gbadura fun awọn eniyan ti o to fun adura ni alẹ yii.

A gbadura fun gbogbo awọn ijọ ati ipejọpọ ti o korajọ lati gbọ Ohun wa kaakiri orilẹ-ede yii, titi de gbogbo ilu ti o wa ni Iwọ oorun, titi fi mọn awọn Oke Arizona, lọ si awọn pẹ̀tẹ́lẹ̀ Texas, titi de Ila-oorun orilẹ-ede yii, kaakiri gbogbo orilẹ-ede yii, Oluwa, nibi ti wọn ti korajọpọ si. Akoko ti olukuluku wa jinna si ara wọn pẹlu ọpọlọpọ wakati, sibẹ, Oluwa, àwá wá papọ ni alẹ yi gẹgẹbi ẹgbẹ onigbagbọ kan naa, ti o n duro de bibọ Mesaya. A gbadura, Baba wa Ọrun, pe ki Iwọ ki O ran An laipẹ fun Ijọ Rẹ. Nitori a beere fun un ni Orukọ Rẹ̀. Amin.

2 Ẹ lee joko.

Mo ki gbogbo eniyan to wa nibi lalẹ yi pẹlu ikini Kristẹni. Mo tọrọ aforiji pe, a si ko wa papọ si ibi ti o kere fun wa, ti a si fun papọ yii, tobẹẹ ti o soro lati mi daradara. Awọn ẹrọ amúlétutù paapaa pẹlu gbogbo isẹ wọn ko to lati se iyatọ pupọ, ero pọ gan an ni. Bi o ba se pe, kiki awọn eniyan to kun ile isin bi o se yẹ ki o ri ni, awọn ẹrọ amúlétutù yii yoo fẹrẹẹ mu eniyan gan. Sugbọn bayi, gbogbo eniyan ni o mu ifatẹgun kan lọwọ lati maa fẹ atẹgun sara, pẹ̀lúpẹ̀lù pe, awọn ẹrọ amúlétutù n fi gbogbo agbara sisẹ.

A ran ikini si gbogbo awọn ọrẹ wa ninu Kristi ti o n fetisilẹ lati gbọ wa lati gbogbo Ila-oorun titi de Iwọ-oorun orilẹ-ede yi. A ki ẹyin ti o wa ni San Jose, Arakunrin Borders, ati ijọ ti o wa nibẹ. A ki awọn ara ti o wa ni awọn oke Prescott, ni Arizona, si Arakunrin Leo Mercier ati ijọ ti o wa nibẹ, ti wọn nduro de bibọ Oluwa. A ki awọn ti o wa ni Tucson, ti wọn korajọpọ lalẹ yii, ti wọn si nduro de bibọ Oluwa. Titi de Houston, Texas, si awọn ti o nduro de bibọ Oluwa. Ni Chicago, si awọn ti o nduro de bibọ Oluwa. Lọ si bebe Okun Ila-oorun, titi de New York, ati Connecticut, ati awọn ipejọpọ nla ti o wa nibẹ ti wọn nduro de bibọ Oluwa. A ko ni aye to nibi yii, ti o lee gba wọn, nitori naa, a saa ni lati ran Ọrọ naa si wọn nipasẹ ẹrọ ibanisọrọ. A ran ikini si Arakunrin Junior Jackson lalẹ yii, ati ipejọpọ rẹ ti o wa ni Clarksville. Ati si Arakunrin Rudell ni opopo 62 ati ipejọpọ rẹ, ti wọn nduro de bibọ Oluwa. Awa si korajọpọ si ile isin wa lalẹ yii, ti a nduro de bibọ Oluwa.

3 Ati bayii, boya ọpọlọpọ yin ni ko si ninu isin lowurọ yii. Mo lero pe, olukuluku ẹni ti ko si ninu isin naa, yoo gba Ohun ti a gba silẹ fun isin naa, ki o si fetisii, nitori mo gbagbọ pe ohun ni Isẹ Ohun Ọlọrun ti a jẹ, to se taara julọ lati igba ti a ti waasu, "Ẹyin Alagba, Akoko wo Niyii?" Mo ni imọlara Imisi Ọlọrun tabi Itami ororo Ọlọrun ati idari lati sọ ohun ti mo sọ ninu iwaasu naa. Iwaasu naa gun, sugbọn a dari mi lati see. Mo si ro pe, Oluwa nipa Ọrọ Rẹ, fi akoko ti a n gbe inu rẹ han wa. O si jẹ ki a loye awọn nkan kayeefi ti o n sẹlẹ wọnyii. O mọn pe, Bibeli wi pe, "Awọn ọlọgbọn yoo loye ohun naa".

Sugbọn awọn orilẹ-ede ati awọn eniyan yoo maa di alailokun ati ọlọgbọn sii. Sa roo wi pe, ọpọ eniyan ilẹ Amẹrika ni o ti ni awọn àmìn ogbó ni ẹni ogun ọdun, wọn dinku ni okun, sugbọn wọn pọ si ni ọgbọn. Wọn ko ni ọkọ ofurufu nigba atijọ, wọn ko si ni awọn ado oloro to lee run odidi ilu tabi orilẹ-ede kan lẹẹkan naa, sugbọn wọn wa laaye pẹ pupọ ju ti isinsinyi. A n dinku ni okun, bi a se n pọ si ni ọgbọn, ọgbọn wa ni yoo si pa wa run. A o o para wa run. Ọlọrun ko ni pa wa run, ọgbọn wa ni yoo pa wa run. Bi o ti se maa nri niyẹn, bẹẹ ni yoo si ri lẹẹkansi.

4 Bayii, nipa ifẹ Oluwa, ni ọjọ aiku to n bọ, emi ko tii mọn ohun ti n o sọrọ nipa rẹ, sugbọn mo n gbẹkẹlẹ Oluwa pe, bi o ba jẹ ki a wa laaye ti ohunkohun ko si sẹlẹ, a o mu iwaasu miran wa ni owurọ ọjọ Aiku ti o nbọ, a o si gbadura fun awọn alaisan ni alẹ rẹ. Lẹhin naa, o jẹ ojuse mi lati pada si Arizona, lati gbe ẹbi mi pada, ki awọn ọmọ lee pada si ile-iwe. Nigba naa, eyin yoo …. A o o fi to yin leti nipa awọn ipade ti o nbọ, akoko ọkọọkan ati ibi ti a o o ti se wọn. Ki Oluwa ki O bukun yin.

Lalẹ yii, a mọn pe ….. Mo ti pẹ lati bẹrẹ pẹlu iseju marundogun, agogo mejọ ti ku iseju marundogun nihin ni Jeffersonville. Iyẹn si jẹ agogo mẹsan ku iseju marundogun ni Ila-oorun oridẹ-ede yii, o si jẹ bii agogo marun-un ni Iwọ-oorun orilẹ-ede yii. Oorun ti fẹ wọ nibi yii. Emi si fẹ ba yin sọrọ kukuru, lati gbiyanju ati ni itamin ororo ti Ẹmi Ọlọrun, lẹhin naa, a oo pe awọn eniyan wa sori ila fun adura.

5 Bayii, mo fẹ ki apejọpọ to wa nibi, ati awọn apejọpọ to korajọ ni ibi gbogbo to ku, ki arakunrin kan ti o ni amin ororo ti Ẹmi Ọlọrun, ni kete ti a ba ti bẹrẹ sii gbadura fun awọn alaisan ki o lọ gbe ọwọ le awọn to wa ninu apejọpọ rẹ. Ranti pe Ọlọrun wa nibi gbogbo. Nitori naa, ni Texas, ati ni Califonia, ni Arizona, ibikibi ti ẹ wa, ẹ gbe ọwọ le awọn alaisan, nigba ti a ba bẹrẹ sii gbadura fun awọn alaisan. O si damiloju pe, Ọlọrun yoo

gbọ, yoo si dahun adura.

Ohun to sajeji kan sẹlẹ ni alẹ ọjọ Aiku ti o kọja, itamin ororo naa si nlọ lọwọ. Ẹmi Mimọ si … Ohun Pataki kan si ni. Emi ko tii ni isin Imọn-nipa-Ẹmi-Ọlọrun fun ọpọlọpọ osu to ti kọja, lati igba ti mo ti wa nibi gbẹyin. Nigba naa, ti mo si jade wa bẹẹ nipa ileri Ọrọ Rẹ….. Iwọ ko mọ ohun ti Ọlọrun yoo se. O ko lee sọ pe, Oun yoo see. Iwọ saa ni lati jade ki o si duro de E. Aseyiowu ni, Oun yoo si se ohun ti wu U. Sugbọn, duro sibẹ ki o si wo ohun ti yo O se, ki o si ni imọnlara Imisi Rẹ bi O se wa si orí ì rẹ.

6 Ati ni opin ipade naa, emi ko si mọ ẹni naa, sugbọn ọkunrin kan ti wa si ori ila adura to jẹ ẹni giga, ti o si pá lori, ti o n saisan pupọ.

Ni igbẹyin, ọkunrin kan farahan ninu iran niwaju mi nibi pẹpẹ. O tẹri rẹ ba, o si njẹ irora, o fọwọ di inu rẹ mu. Mo si ro wi pe, o ni lati jẹ ọkunrin akọkọ tabi ekeji ti mo ti gbadura fun nitori pe o pa lori, ẹni ti mo ri ninu iran yii tẹ ori rẹ ba, ọkunrin naa tobi, o n jẹrora. Mo wo yika lati ri ọkunrin ti mo gbadura fun yẹn, mo ri i ti o joko ninu apejọpọ ti o n yọ. Mo wa ro o wi pe, "ibo ni ẹni yi wa?" Emi ko si mọn ibiti o wa. Mo ni imọlara rẹ, mo si nri ọkunrin yii niwaju mi nipa iran. Mo se akiyesi pe, onfa naa fa mi si ọwọ ẹyin, mo si mọ pe, apá ẹ̀yìn mi ni ẹni naa wa. Mo wo Arakunrin Neville ati awọn meji to joko sẹyin mi, ki i se awọn. Mo wi pe, "Ọkunrin naa wa ninu iyara ti a ti ma a nse iribọmi yẹn". Njẹ ẹ mọn ẹni ti i se? Arakunrin Shepherd ni. Idi ti n ko fi tete mọn pe oun ni ni pe, o joko sibẹ, o si tẹriba, o ngbadura.

O ro wi pe oun yoo ku, o tilẹ ti nro bẹẹ fun ọsẹ melokan. Iyawo rẹ sọ fun un pe ki o lọ ra bata tuntun, o si dahun pe, "Emi ko nilo wọn, emi ko ni wa laye yi pẹ to yẹn".

7 O si pade mi ni ijelo ni ile Arakunrin Wood ti o n yin Ọlọrun pẹlu ariwo. O wi pe, "Emi njẹ ẹran ẹlẹdẹ, ẹyin, tomati, ohunkohun ti mo fẹẹ jẹ".

O si fi irẹlẹ fi ijoko rẹ silẹ fun ẹlomiran lati joko, o lọ joko si ẹyin nibẹ, lati fun awọn eniyan ni aaye, o si ngbadura. Se o ri i, iwọ ko nilo kaadi adura, igbagbọ nikan ni o nilo. Bayi, emi ko mọ boya a mu un larada ninu iran naa, tabi bẹẹ kọ. Mo kan saa wi pe, ọkunrin ti o n gbadura, ohun kan si n dalaamu". Mo ro pe, Ẹmi Ọlọrun darukọ ohun ti o see. "Aisan inu, ti o si n gbadura ni ẹyin mi yii. Jesu Kristi Oluwa mu ọ larada". Bayii, ohun ti mo lee sọ gẹlẹ ni yii. Ohun ti onfa naa sọ ni pe, o n gbadura. Mo lee ri iyẹn, sugbọn emi ko mọ ohun ti yoo sẹlẹ, se o rii.

Sugbọn, nigba ti o ba gbọ "Bayii ni Oluwa wi", gbogbo eniyan ni o mọn eleyi, kii se emi ni o sọrọ nigba naa, Oun ni.

8 Sugbọn emi maa nsọ pe, "Jesu Kristi ti mu ọ larada," otitọ pọnbele ni iyẹn. "A ti pa A lara fun aisedeede wa, nipa ina Rẹ, a ti mu wa larada". Se o rii?

Sugbọn, nigba tí Ó ba wi pe, "Bayii ni Oluwa wi" ti O si sọ fun ọ, ohun ti iwọ ni lati se, ati ohun ti yoo sẹlẹ, kiyesi iyẹn, yoo ri bẹẹ gẹgẹ.

Sugbọn, nigba ti mo ba sọ wi pe "Jesu Kristi wo ọ san, O si mu ọ larada." Iwọ gbagbọ, nitori pe, O ti sọ ọ tẹlẹ. Emi sá n tunsọ, ohun ti O ti sọ ni.

Ìrán jẹ́, títún sọ, ohun kan ti O fihan mi. O ye ọ bi?

9 Bayii, ẹ jẹ ki a yara kankan ki a si wọ inu iwaasu Ọrọ naa, nitori mo mọn pe, ọpọ ẹyin ti o wa nibi ni ẹ si ni lati rin irinajo to jina lalẹ yii. Mo gbadura pe ki Ọlọrun bukun yin, ki o si ran yin lọwọ, ki o si dabobo yin ni gbogbo oju popo naa. Bayii, mo fẹ sí sí Ihinrere ti Matthew lalẹ yii, ori kọkanlelogun, ẹsẹ ikin-in-ni si ikọkanla. Bayii, ti iwọ ko ba ni Bibeli rẹ, tabi iwọ fẹ kọ awọn ibi ti a ka silẹ, o dara.

10 Bayii, ẹyin ti ẹ ko gbọ iwaasu ti owurọ yii, ti ẹ ni ẹrọ ìgboùn-sílẹ̀ kan, awa kii bẹbẹ fun tita ohun ti a fii gbohun silẹ (teepu). A kii polowo ohunkohun fun tita. Nigba miiran, ninu ipade isọji nla kan, wọn yoo kede pe awọn iwe kan wa ni ẹyin lọhun yẹn fun tita. A kii jere lori wọn. Arakunrin Vayle ni o kọ wọn. Ọkunrin ti o se alakoso awọn àwo (teepu) ti a fi n gbohun silẹ yii, yoo sọ fun yin, a kii pawo lori awo igbohunsilẹ naa. Ki i se awọn awo igbohunsilẹ yii lo se pataki, Isẹ Ohùn Ọlọrun ti ọjọ oni lo se pataki. Nigba ti ọkunrin kan ba si ni lọkan pe, owo lo se pataki, ko ni se isẹ gbigba Ohun silẹ mọn. Otitọ ni. Mo beere nipa rẹ, mo ro pe, teepu igbohunsilẹ wa ko pe dọla marun-un. Kin ni o wi? Dọla mẹta tabi mẹrin fun awọn iwaasu gigun yẹn.

Mo si beere nipa oniwaasu kan, teepu igbohunsilẹ rẹ ni wọn n ta ni dọla mẹsan fun iwaasu ogun isẹju si ọgbọn isẹju.

11 Nitori naa mo ri wipe, Arakunrin wa Sothman ni ibiyi ko maa sọ ara rẹ di olowo, tabi eyikeyi ninu awọn ara wọnyi, nipasẹ tita awọn teepu igbohunsilẹ ti wọn nse yii. Se o rii, wọn npa iye owo ti wọn nilo lati le ma a se lọ. Emi ko lee sọ pe ki wọn se e lọfẹ, nitoripe, wọn ni lati ra awọn teepu igbohunsilẹ naa ati awọn nkan

miiran. Ẹrọ ti wọn fi nsisẹ naa wọ́n pupọ, o na wọn ni bi i ẹgbẹrun mẹwa dọla lati ko irin isẹ naa jọ lati lee bẹrẹ rara.

Bayii, wọn ko ti i filọ, sugbọn a fi ye mi pe, awọn igbimọ ijọ yoo tun joko laipẹ lati se agbeyẹwo nipa ẹni ti yoo maa se igbohunsilẹ ati tita rẹ. Wọn maa n se ipade naa, lati igbadegba. Emi ko ba wọn joko ri. Wọn yoo pe fun idunadura pẹlu awọn to nifẹsi isẹ naa. Ẹnikẹni ti wọn ba si yan, wọn yoo kọ iwe si ẹni naa, oun ni yoo maa se igbohunsilẹ. Emi ko mọn ju eleyi lọ nipa rẹ. Awọn ni o n bojuto iyẹn, emi ko tilẹ ri aye se yiya awọn ọmọ ọwọ si mimọ, ki a maa wa sọ ti gbigba ohun iwaasu silẹ, tabi sise itẹbọmi.

12 Nitori naa, mo ti fi gbogbo ọkan mi sinu Isẹ Ohun Ọlọrun yii. Eyi ni onfa kẹta ni, ti mo gbọdọ se olooto̩ si pe̩lu gbogbo ò̩wò̩.

Mattiu 21:1-11. Mo so ìye̩n ki iwo̩ lee si Iwe Mimọ.

*Nigba ti wo̩n sumo̩n eti Jerusalẹmu, ti nwo̩n de Betfage ni Oke Olifi, nigba naa ni Jesu ran awo̩n o̩mo̩ e̩hin Re̩ meji lo̩.*

*O wi fun wo̩n pe, E lo̩ si ìletò ti o kojusi yin, logan, eyin yoo ri ke̩te̩ke̩te̩ kan ti a so ati, o̩mo̩ re̩ pe̩lu: e̩ tu wo̩n, ki e̩si fà wo̩n fun mi wá.*

*Bi e̩nike̩ni ba si wi nkan fun yin, e̩yin yoo wi pe, Oluwa ni fi se: lóg̣an ni yoo si ran wo̩n wa.*

*Gbogbo eyi ni a se, ki eyi ti a ti so̩ lati e̩nu wolii wa ki o le se̩ pe.*

*E̩ so̩ fun o̩mo̩binrin Sioni pe, kiyesii, O̩ba re̩ nbo̩ wa so̩do̩ re̩, o ni ire̩le̩, o joko lori ke̩te̩ke̩te̩, ati lori o̩mo̩ ke̩te̩ke̩te̩.*

*Awo̩n o̩mo̩ e̩hin naa si lo̩, wo̩n se bi Jesu ti wi fun wo̩n.*

*Wo̩n si fa kete̩ke̩te̩ naa wa, ati o̩mo̩ re̩, wo̩n si té̩ aso̩ wo̩n si e̩hin wo̩n, wo̩n si gbe Jesu ka a.*

*Opo̩ ijo̩ eniyan te̩ aso̩ wo̩n si o̩na: e̩lomiiran se̩ e̩ka igi we̩we̩, wo̩n si fo̩n wo̩n si o̩na.*

*Ijo̩ eniyan ti nlo̩ niwaju ati eyi ti nto̩ wo̩n le̩hin, nkigbe wi pe, Hosanna fun o̩mo̩ Dafidi: Olubukun, ni e̩niti nbo̩ wa ni Oruko̩ Oluwa: Hosanna loke o̩run.*

*Nigba ti o de Jerusalẹmu, gbogbo ilu mi titi, wi pe, Ta ni yii?.*

*Ijo̩ eniyan si wi pe, Eyi ni Jesu, Wolii lati Nasare̩ti ti Galili.*

Bayii, bi emi ba fe̩ mu akori iwaasu lati inu eleyi, fun nkan bi ọgbọn iseju, ki a to bẹrẹ si i gba adura fun awọn ti a to fun adura: emi fe̩ mu eleyi fun akori iwaasu: Kin Ni Ifamo̩ra Ni Ori Oke Naa?

13 Bayii, o je̩ ojo̩ aare̩, ati aibale̩ ara kan, o si je̩ ojo̩ kan ti o yato̩. A ri i ti Jesu nbo̩ wa si Jerusalẹmu fun Ajo̩ Irekọja. Ajọ irekọja si ni ibi ti a ti pa O̩do̩-aguntan ti Irekoja naa, ti a si wọn eje̩ re̩ si ite̩ aanu fun etutu fun awọn eniyan. O si ti wa lati Betfage si ori Oke Olifi, ti o ga ju ori oke miiran ti a ko̩ Jerusalẹmu le lori. Bi O se wò, O mọn wi pe, eyi ni irinajo Oun ti o gbẹyin si Jerusalẹmu.

Eyi ni akoko naa ti wo̩n yoo fá Á lé àwo̩n e̩le̩se̩ lo̩wo̩, tí wo̩n yóó sì pá Á. Oun yoo ku iku to buruju lo̩ ti eniyan alára kíkú kan tí ì kú rí, a óó sì sín Ín. Awo̩n tirè̩ ni yoo fihan fun o̩ta lati mu U, ti die̩ ninu wo̩n si duro pe̩lu Re̩. Bi Oun si ti jẹ Ọlọrun, O mọn ohun ti o wa ninu ọkan wọn, O si mo̩n e̩niti yoo fihan lati ibe̩re̩. Oun si mo̩n wi pe, o̩kunrin ti o duro ti Oun, ti o joko ti I, ti o si n ka Owo Re̩ fun Un, ati be̩e̩be̩e̩ lo̩, Oluwa si mo̩n wi pe, o̩kunrin yii ni yoo fi Oun han. O si mo̩n wi pe agbelebu Roomu buburu kan duro de Oun nibe̩. O mo̩n wi pe omi ati eje̩ inu ara Oun yoo ya so̩to̩o̩to̩, ati pe ìro èjè̩ yoo kan silẹ niwaju ori Re̩ bi òógùn. O mo̩n pe gbogbo eleyii wa niwaju Oun. O si duro lori oke naa, O wo Jerusalẹmu.

14 Awo̩n eniyan ojo̩ naa - awo̩n tí wó̩n pè ní e̩gbe̩ e̩lé̩sìn to dara julo̩ ni ojo̩ naa - korira Re̩. Awo̩n ijo̩ ojo̩ naa korira Re̩, wo̩n si ko̩ O̩ pe̩lu gbogbo awo̩n to fetisile̩ lati gbo̩ O̩ro̩ Re̩. Bi e̩nike̩ni ba si lo̩ si ipade-ipolongo-iwaasu Rẹ, wo̩n yoo yo̩ e̩ni be̩e̩ kuro ninu ijo̩ wo̩n le̩se̩ke̩se̩. Ko ya ni le̩nu ti Iwe Mimo̩ fi wi pe, “O to̩ awo̩n tirẹ wa, awọn tirẹ ko si gba A”. Awo̩n to ye̩ ko fẹran Rẹ, awọn to yẹ ko duro ti I, awo̩n gan an ni o̩ta Re̩ to buru julo̩.

15 O si ti ko e̩gbe̩ kekere ti o te̩le E jo̩ lati aarin awo̩n talaka, awo̩n apeja, awo̩n agbowo ode, awo̩n ti ko kawe. Bibeli wi pe, awo̩n kan ninu wo̩n tile̩, je̩ alaimo̩nkan ati alaikawe. Ẹlomiiran ninu wọn ko tile̩ lee da oruko̩ re̩ kọ. Oun ko fi igba kanri lo̩ sinu ijo̩ lati lo̩ mu awo̩n tirẹ.

Ko si fi igba kanri wa ni irẹpọ̩ pẹlu awọn oludari ijo̩. Yato̩ si eleyi, o tẹle ilana ti awọn wolii ma a nto̩. Ó dá

ohun gbogbo ti wọn se Iébi, gẹgẹ bi awọn wolii to saaju Rẹ ti se, nitori pe wọn jẹ ara Ọrọ naa, Oun si ni ẹkunrẹrẹ Ọrọ Naa.

16 Sugbọn laarin gbogbo nkan wọnyi, ni igba ijọ kọọkan, ati gbogbo wolii to tii wa ri, tabi to tii wa saye, awọn eniyan kan yoo wa, ti a yantẹlẹ lati gbọ isẹ Ohun Ọlọrun naa, wọn yoo si tẹlẹ E. Awọn wọnyi ki i tẹle ọpọ èrò. Wọn ki i kọbiara si atako lati ọdọ awọn alaigbagbọ. Wọn ko ni ariyanjiyan pẹlu wọn. Oun kan soso ni o jẹ wọn logun, eyi si ni lati gba Ọrọ naa gbọ ati lati ri gbogbo Ọrọ naa ti wọn ba lee ri, ki wọn gba gbogbo rẹ si ọkan wọn gẹgẹbi Maria, ẹni ti o joko si ẹsẹ Jesu.

Matha si n pese onjẹ irolẹ fun Un, Jesu si wi pe, “Sugbọn Martha, iwọ n se àníyàn ju nipa awọn ohun aye yii, sugbọn Maria ti safẹri ohun ti o dara julọ” Se o rii, awọn ohun Iye Ainipẹkun.

17 Bayii, a ri i wi pe, ọpọ awọn eniyan ọjọ naa ti ni oye ohun ti yoo sẹlẹ…. Wọn ko ni iwe iroyin bi ti ọjọ oni, wọn ko ni apoti esu mohun-maworan, tabi ẹrọ ibanisọrọ, tabi ohun kan bẹẹ ni igba naa. Sugbọn, o jẹ ohun kan ti wọn ti sọ kaakiri laarin awọn eniyan wi pe, Oun yoo wa nibi Ajọ Irekoja yii. Nitori pe, ọpọ awọn eniyan naa ni o jẹ ẹni ẹmi, ti wọn si mọn pe, Oun gan an ni Ọdọ-Agutan fun Ajọ Irekoja naa, nitori pe, O ti sọ awọn ohun ti yoo sẹlẹ fun wọn.

18 Ati pẹlu, niwọn igba ti wọn ti mọn wi pe, Oun yoo wa nibẹ, ti wọn si nifẹ Rẹ bi wọn se nifẹ Rẹ yii, wọn n duro de E. Awọn èrò kan si wa, ti wọn ti n wọna, ti wọn si n kaakiri oju popo, nitori wọn mọn wipe, Oun yoo farahan laipẹ. Wọn n fojusọna.

Awon miiran si n ro o wi pe, kin ni ohun to n se awọn eniyan tí wọ́n n rọ́ káàkiri lati ojule de ojule wọnyi ? “kin ni ohun to n fawọn mọra”.

Awọn ero yii, yoo tun wo ọtun, wọn yoo tun wo osi, bi ẹni pe, wọn nwa ohun kan. O dabi ẹni pe, wọn n wa ohun kan, wọn wa ni ifojusọna fun ohun kan ti yoo sẹlẹ.

Ah! o wumi ki n tilẹ yi akori iwaasu mi pada ni isisinyi ki n si sọ eleyi, pe ohun to nsẹlẹ loni gan niyii. Awọn eniyan ti o nwọna fun bibọ Rẹ wa ni abẹ ifojusọna ati ireti. A ni imọnlara rẹ, inira-aibalẹ-ara nitori ifojusọna naa. Wọn si n sawari, wọn n se akiyesi finifini si gbogbo isẹlẹ kọọkan, ati amin kọọkan, wọn n fi we Iwe Mimọ.

19 Nigba ti wọn si ri ohun gbogbo ti a ti sọtẹlẹ ni pa Rẹ, ti gbogbo rẹ ti fẹrẹ ẹ sẹ tan, wọn mọn pe, opin sunmọn etile. Wọn fẹ wa nibẹ, nitori naa, wọ́n n wò pẹlu afiyesi gidi. Diẹ ninu awọn ero naa gbagbọ ninu Rẹ, Sugbọn wọn ko pọ. Awọn kan lodi si I, awọn to si pọ ju niyii. Ida mẹsan ninu idasi-mẹwa, ni o lodi si I.

Bi o si ti ri loni naa niyii laarin awọn èrò ẹlẹsin. Nigba ti ó bá kan Ọrọ Ọlọrun gan-an ati Kristi, ida kan ninu ọgọrun ni yoo gbaagbọ. Awọn to ku ko ni kọbi-ara-sii, ohun yoo-wu ki a se, wọn yoo kaa si ọrọ awada kan, tabi ki wọn saa sọ ohun kan lodi si I. O dabi o se ri nigba yẹn. Nkan kii fi bẹẹ yipada, ohun to ti sẹlẹ tẹlẹ ri ninu itan tun maa n sẹlẹ.

20 A rii wi pe, ireti yii mu aibalẹ ara wa. O ni lati ri bẹ ẹ. O gbọdọ se bẹẹ. Wọn n duro ni ifojusọna, wọn si n fọkan daniyan wi pe, kin ni yoo se gan-an nigba to ba de. Wọn fẹ mọn ọn. Wọn fẹ rii. Wọn gba A gbọ. Awọn miiran si ti gbọ wi pe O n bọ, wọn si lọ sibẹ lati fi se ẹlẹya. Nitori naa, lẹyin gbogbo ifojusọna pẹlu aibalẹ ara, ọjọ to sajeji kan, akoko to sajeji, ti awọn ijọ ti sun lọ, ti ara awọn eniyan ti kan nipasẹ ifojusọna, ọpọ awọn eniyan lo ti wa nibẹ, lojiji, isẹlẹ naa sẹlẹ.

21 Lati ori oke Olifi, a ri kẹtẹkẹtẹ funfun kan ti o n bọ, to n rin sọkalẹ oke naa, pẹlu awọn eniyan kan ti wọn n kigbe bi alakatakiti ẹlẹsin, wọn n ge imọ̀n ọ̀pẹ ati ẹka igi wẹwẹ, wọn n ju asọ wọn, ati awọn ẹka igi si oju ọna, wọn si n kigbe pe, “Hosanna si Ọmọ Dafidi, ti n bọ ni Orukọ Oluwa!” Ẹni ti o gun kẹtẹkẹtẹ yii, kii se ẹlomiiran bikose Mesaya wakati naa, ti Ọlọrun fi Ororo yan.

Kin ni Ọlọrun nse nigba naa? Kin ni Ifamọra yẹn lori Oke naa? O jẹ Ọlọrun, ti O nkọ Itan, Ọlọrun nmu isọtẹlẹ sẹ. Eyi si maa n mu ki ifamọra sẹlẹ. Eyi n mu ki gbogbo awọn alatako korajọpọ, awọn igun, (ti iwaasu owurọ yi) ati awọn idi pẹlu. Se o rii? Wọn wa papọ lati se iwadi pe, kin ni o n sẹlẹ gan an? Awọn kan n wa lati wadi ki wọn lee mọn ohun to sẹlẹ, awọn kan si wa lati se atako. Orisirisi ni wọn korajọpọ, gẹgẹbi a ti sọ ni owurọ yii. Onigbagbọ, alafẹnujẹ onigbagbọ ati awọn alaigbagbọ. Kin ni o wa lori oke naa? A n mu Isọtẹlẹ sẹ. Bayii, a oo ri nkan to sẹlẹ.

22 Bayii, ninu Iwe Sekariah, ori kẹsan, ẹsẹ ikẹsan. Sekariah, ti o jẹ ọkan lara awọn wolii, sọrọ nipa Ẹmi Ọlọrun, o wi pe:

Yọ gidigidi, Iwọ ọmọbinrin Sioni, ho, Iwọ ọmọbinrin Jerusalẹmu: Kiyesii, Ọba rẹ n bọ wa sọdọ rẹ, ododo ni Oun, O si ni Igbala; O ni irẹlẹ, O si n gun kẹtẹkẹtẹ, ani ọmọ kẹtẹkẹtẹ.

Bayii, kin ni o se awọn akọwe yẹn? Kin ni o se awọn alufaa yẹn? Kin ni o se awọn eniyan ẹlẹsin yẹn? A ti kọ eyi silẹ ni irinwo ọdun o le mẹta-din-laadọrun, ki o to sẹlẹ. A si kọ lati ọwọ wolii kan ti a ti jẹrigbe, a si kọ ọ sinu Bibeli, Iwe Mimọ Majẹmu Laelae. Kin ni o de ti wọn ko fi rii wi pe isọtẹlẹ niyii ti o si nsẹ ni ọjọ yẹn? Idi kan naa ti wọn ko fi rii loni. Wọn ti sọ Ọrọ Ọlọrun di alailagbara si awọn eniyan, nipa kíkọ́ ni, ní àsà eniyan fun ẹ̀kọ́ òpómúléró ijọ.

Bi awọn akọwe, oniwaasu, iransẹ Ọlọrun ati awọn to pe ara wọn ni ẹni ẹmi, awọn ẹni amin ororo, ba lee ka Bibeli, awọn ohun ti o nsẹlẹ ko ni maa se wọn ni kayeefi. Wọn iba ti mọn wipe, Ọlọrun ni O n mu Ọrọ Rẹ sẹ.

23 A nkọ itan silẹ ni, a n mu Isọtẹlẹ sẹ. Igbala nde fun araye, ọjọ nla naa, ti gbogbo awọn wolii ti fojusọna si. Gbogbo awọn to wa ninu iboji n duro de ọjọ naa (ronu nipa rẹ), gbogbo awọn to ti ku, gbogbo awọn olododo, ati awọn ajẹri-iku ati gbogbo awọn wolii.

Oun sẹsẹ kigbe sita ni wi pe, “Iwọ Jerusalẹmu, Jerusalẹmu, iwọ ti o sọ olukuluku awọn wolii ti Mo ran si ọ ni okuta, ti o si pa awọn olododo, bawo ni Emi I ba ti radọ bo ọ bi adiyẹ ti i radọ bo awọn ọmọ rẹ, sugbọn iwọ ko gba! Sugbọn bayii, wakati rẹ ti de”.

24 Gbogbo awọn ti o wa ninu iboji - Abrahamu, Isaaki, Jakọbu, gbogbo awọn wolii - ni wọn n duro de wakati yii.

Ijọ si fọju si I. “Tani eleyi ti o n fa gbogbo ariwo wọnyi?” Tani ẹni yii, ti wọn sọ nipa Rẹ ni igba kan pe, Eyi kii a se ọmọ gbẹnagbẹna bi? Awa mọn Ọn. Nibo ni Oun ti ri Ọgbọn yii? Kin ni! Awa ko rii ki o lọ si ọkan ninu awọn ile iwe wa. Awa ko mọn iwe kankan ti o kẹkọ ninu rẹ ri. Ta ni gan-an?“

Oun ni idahun si gbogbo isọtẹlẹ awọn wolii. Oun lo nbọ yii, O n gun ọmọ kẹtẹkẹtẹ. Iru Ifamọra nla wo ni yii! Ọlọrun n mu Ọrọ Ileri Rẹ sẹ. Akoko ti a ti nreti lati ẹgbẹrun mẹrin ọdun sẹyin. Ninu Jẹnẹsisi Ori kẹta, ẹsẹ ikarun-dogun. Ọlọrun sọtẹlẹ wi pe, Iru obinrin Naa, yoo fọ ori ẹranko-to-pada-dejo nì, sugbọn ori rẹ yoo pa gigisẹ Iru obinrin Naa. Isọtẹlẹ yẹn, ti a ti sọ ninu gbogbo Iwe Mimọ nipa bibọ Ọkunrin yii.

25 Ati laipẹ si akoko yii, wolii kan dide laarin wọn ti a jẹrigbe gẹgẹbi wolii, ti orukọ rẹ n jẹ Sekariah. O si wi pe, “Ẹyin ọmọbinrin Jerusalẹmu, ẹyin ọmọbinrin Sioni, ẹ yọ, ẹ kigbe, ẹ pariwo soke, nitori Ọba rẹ nbọ wa ba ọ pẹlu iwatutu, iwa pẹlẹ ati irẹlẹ, o n gun ọmọ kẹtẹkẹtẹ.”

Ati nibi yii, awọn eniyan ti wọn nka Iwe Mimọ yii, lojoojumọ ri I ti o gun kẹtẹkẹtẹ wọle, wọn si kigbe pe, “Tani yii?” Se o rii, Ọlọrun ni O n mu Ọrọ Rẹ sẹ si awọn eniyan to yẹ ko mọn ohun to jẹ, sugbọn wọn ko mọn ọn.

Nigba ti Ọlọrun ba mu Ọrọ Rẹ sẹ, nigba gbogbo ni o maa nfa ifamọnra; nigba gbogbo lo n se e. O n fa ifamọnra, nitori pe o maa n sajeji. O maa n sajeji pupọ nigba ti o ba mu Ọrọ Rẹ sẹ si awọn eniyan to kun fun àsà ìgbàlódé ti ọjọ naa, nitori pe awọn alásà ìgbàlódé ti ọjọ naa ko gba Ọrọ naa gbọ. Wọn ni ọna tiwọn to lodi si I.

26 Bayii a rii… Ẹ jẹ ki a lọ si inu Iwe Mimọ ki a si wo awọn isẹlẹ to sajeji miiran, fun iseju diẹ, nibiti Ọlọrun ti mu awọn isọtẹlẹ Rẹ sẹ. Nigba ti Ọlọrun ba sọ ohunkohun, Oun yo o s e e. Gbogbo ọrun ati aye yoo koja lọ, sugbọn Ọrọ yẹn ko lee lọ lai sẹ. Nitori naa, eyi maa nfa isẹlẹ to fanimora, isẹlẹ to sajeji, to si fanimọra.

Kiyesii, bi Ọrọ Ọlọrun se dabi ohun kan ti ko mọgbọn dani loju awọn eniyan to yẹ ko gba A gbọ, sibẹ, o sajeji si wọn, tobẹ ẹ gẹ, wọn kigbe wi pe, “Họwu, kin ni eyii?” Nigba ti o yẹ ki wọn maa kigbe wi pe, “Hosanna si Ọba ti O n bọ ni Orukọ Oluwa”. Sugbọn iwọnba eniyan perete ni O nse eleyii, awọn eniyan diẹ. Imusẹ isọtẹlẹ kan ti o ti wa lati ẹgbẹrun mẹrin ọdun, nipa isẹlẹ to ga julọ ti o lee sẹlẹ si orilẹ-ede naa, nitori pe gbogbo awọn tí ó ti kú gbẹkẹ wọn le e, gbogbo ireti ọjọ iwaju wọn wa ninu rẹ, awọn ẹlẹsin ti wọn sọ pe awọn gbagbọ si n kigbe pe, “Tani ni yii? Kin si ni ifamọra yii.?” Ohun kan to sajeji! Bi o ti se maa n ri niyii, ko yipada bayii, kayeefi ni.

27 Ẹ jẹ ki a wo diẹ ninu awọn isẹlẹ kayeefi to ti sẹlẹ ri, gẹgẹbi mo ti sọ laipẹ yii. Kin ni ifamọra naa, nigba ti o ku diẹ ki idajọ kọlu aye, ti a si fi omi paarun? Baba arugbo kan ti o to ẹni ogọfa ọdun nkan ọ̀kọ̀-ojú-omi kan nigba ti kò sì sí omi ti ọkọ̀ naa yoo lefo le lori. Fun ọpọlọpọ ọdun, o duro lẹnu ọna ọkọ naa, o si nkan inu rẹ, o si n fi ọ̀dà kíki kùn ún ninu ati ni ode. O si wi pe, “Omi yoo bo gbogbo aye mọlẹ”, ni akoko kan to kun fun imọn ijinlẹ.

“Kin ni ariwo kikan ohun kan ti o ndun lori oke lọhun yẹn?”. “A. Ọkunrin arugbo kaa ti o njẹ Noa ni o ti duro ninu oorun pẹ ju: oorun si ti ba ọpọlọ rẹ jẹ. Ko si mọn ohun ti o nse mọn. O si nkọ́ ohun kan ti o pe ni 'ọkọ kan', o si wi pe, omi nbọ lati ofurufu nibiti ko si omi, omi yii yoo si pọ to bẹẹ ti yoo fi gba gbogbo awọn eniyan lọ. Gbogbo ẹni ti ko ba si ti gba a gbọ, ki o wọ inu ọkọ rẹ ni omi yoo parun. Ta ni o ti gbọ ohun bi eleyi

ri". O jẹ ifamọra kayeefi kan.

28 Mo tilẹ roo wo pe, nigba ti awọn eniyan ba fẹ rẹrin daradara, wọn yoo lọ siwaju ọkọ naa, wọn a si rẹrin. Wọn a sọ fun Noa pe, "Sebi, iwọ sọ pe ojo yoo rọ ni ọgọrun ọdun seyin. Baba, baba mi sọ fun mi pe, oun gbọ ti o sọ pe ojo yoo rọ, iwọ si n kan nkan sibẹ ninu pako atijọ yii. Iwọ ko se jẹ ki ori rẹ pe?".

Sugbọn, Ọlọrun ni o n gbaradi lati fẹsẹ ileri kan mulẹ, ki o si mu isọtẹlẹ ti wolii Rẹ ti sọ wa si imusẹ. O sajeji pupọ! Ọlọrun n mu ileri Rẹ si Noa sẹ, nigba ti awọn toku n fi rẹrin. Bẹẹ ni Ọlọrun tun ngbaradi, lati kọ itan, lati fihan awon to ku, ani titi de ojọ oni, pe Oun maa npa Ọrọ Rẹ mọn. O nfi se apẹẹrẹ, nipasẹ baba arugbo yẹn to nkan ọkọ, fun awọn eniyan America lalẹ yii, ati fun gbogbo aye. Laibikita ohun ti imọn ijinlẹ le e sọ, ohunkohun ti wọn sọ (eyi, iyẹn, tabi ohun miiran), Oun si npa Ọrọ Rẹ mọn sibẹ. O n kọ itan silẹ ni.

29 Kin in ifamọra ni ojọ kan….Ohun kayefi kan sẹlẹ ninu aginju, eyi si jẹ igbo kan ti o n jo. Wolii kan to ti salọ kuro lọdọ awọn ara rẹ ni o duro nibẹ, ninu aginju. Ko gbọ ohun kankan, bẹẹ ni ko gbọ ohunkohun, sugbọn o wo, o si ri ohun kayeefi kan ni ori oke naa. Ọlọrun ni O n pe akiyesi rẹ, lati faa mọra. Bẹẹ gẹlẹ lo ri loni.

Ọlọrun ti setan lati mu Ọrọ Rẹ sẹ ti o ti sọ fun wolii Rẹ Abrahamu pe: "Iru ọmọ rẹ yoo se atipo ni ilẹ ajeji fun irinwo ọdun, Emi yoo si mu wọn jade kuro pẹlu ọwọ agbara nla".

O si n pese ọkunrin kan silẹ fun isẹ naa, gẹgẹbi O ti n pese ibi ààbò kan fun gbogbo awọn ti yoo gbagbọ. Ọlọrun lo jẹ ki Ina yẹn maa jo ninu igbo naa, O si mu ki darandaran yii, tii se Mose ki o wi pe, "Emi yoo ya si ibiyi lati wo ohun kayefi yii ati itumọn rẹ. Nigba ti O si mu ki Mose wa si ibi igbo naa, O sọrọ sii.

30 Kin ni ifamọnra naa, nigba ti o se, ni gbọngan Pilatu (Farao), nigba ti darandaran yii ju ọpa kan silẹ ti o si di ejo? Ọlọrun n mu ileri Rẹ sẹ fun Mose. Kin ni ifamọnra naa ni Okun Pupa, nigba ti ipàyà, tabi ìbẹ̀rùbojo ba awọn ẹsin Farao, nigba ti wọn rii, ti iji kan wa lati Ọrun ti o si pin Okun pupa niya sọtun sosi, ẹgbẹ awọn eniyan kan ti o jẹ ẹru si nrin kọja ninu ojuse wọn si Ọlọrun lori ilẹ gbigbẹ. Kin ni? Ọlọrun ni o n mu Ọrọ Rẹ sẹ. Ohun ti o lee pa wọn, ani okun pupa ya kuro lọna, awọn alaaye eniyan yii si rin kọja, awọn eniyan miiran to jẹ oku nipa tẹmi si gbiyanju lati farawe wọn, wọn si ri sinu okun. Ọlọrun ni o n mu isọtẹlẹ sẹ, ti o si nkọ itan silẹ. Eyi ni ifamọnra ni eti okun pupa.

31 Kin ni ifamọra ni ọjọ keji lẹhin eyi ni Oke Sinai, nigba ti a pase fun gbogbo awọn eniyan naa, láti má sunmọ awọn iyawo wọn, sugbọn ki wọn fọ asọ wọn, ki wọn ya ara wọn si mimọ, ki wọn si ko ara wọn jọ yi oke naa ka, nibiti ọkunrin ti a n pe ni Mose yii ti sọ pe oun ti pade Ọwọn Ina kan. Ọlọrun si ti sọ fun Mose pe, "Emi yoo sọkalẹ wa saarin awọn eniyan naa. Emi yoo fi ẹsẹ ohun ti Mo sọ fun ọ mulẹ, ati Ẹniti Emi I se; Emi yoo fihan wọn pe, Emi ni Ọlọrun". Eyi ni ifamọra naa: Ọlọrun n mu Ọrọ Rẹ sẹ.

32 Kin ni ifamọra ni ọjọ kan ninu itan, nigba ti orilẹ-ede kan ti gbagbe Ọlọrun, nigba ti awọn eniyan naa ti di alasa lasan ati alaibikita, nigba ti awọn alufaa ti tẹlẹ ọna igbalode, ti awọn wolii si sọtẹlẹ gẹgẹbi ifẹ inu awọn alufaa? Ni ọjọ naa, bi o ti maa n ri, wọn ni ọkunrin kan ti wọn ro pe o ti gba-were-mẹsin. O sọrọ lodi si bi awọn obinrin se n fi ọda kun oju wọn ati awọn nkan bẹẹ. O si jẹ ẹnikan ti ọrọ tirẹ yatọ si ti gbogbo eniyan. Ọkunrin arugbo yii si ti sọ fun Ọba wi pe, "Iri lasan ko ni sẹ, afi igba ti mo ba to pe fun un".

33 A si rii wi pe, oun ti sa lọ sinu aginju nibi kan lati fi ara pamọ. Awọn eniyan si ro wi pe, o nilati jẹ pe, ebi ti paku sibikan, sugbọn, a ti bọ ọ pẹlu ounjẹ ati omi daradara. Oun si jade wa, o wi fun wọn pe, "Se ẹ rii bayii wi pe, mo ní, "Bayi ni Oluwa wi?" Bayii, bi ko ba tii da yin loju, ẹ jẹ ki a lọ si ori oke ki a si lọ fi daniloju; "Ẹni ti o jẹ Ọlọrun". Nitori o ti ri iran miiran lati ọdọ Oluwa.

O wi pe, "Ẹ se pẹpẹ kan, ẹ si yan ẹgbọrọ akọ maluu kan, ki ẹ paa. Emi yoo si kọ pẹpẹ Oluwa, emi yoo fi ẹgbọrọ akọ maluu kan si ori rẹ. Awa mejeeji yoo se irubọ, si jẹ ki Ọlọrun to jẹ Ọlọrun tootọ fi ina dahun". Ohun ko ba ti se eleyi rara bikose pe, Oluwa ti sọ fun un. O sọ bẹẹ lẹyin o rẹyin. O wi pe, "Oluwa, emi ti se eleyi ni igbọran si asẹ Rẹ".

34 Sugbọn kiyesi ifamọra naa. O ti ni irinwo awọn alufaa ti wọn duro lori oke naa, ati ọba ti o wa ninu kẹkẹ rẹ, pẹlu gbogbo ohun ihamọra ati awọn ẹsọ rẹ ti o duro yii ka. Ọkunrin arugbo yii, ti oju rẹ kun fun irun, ti oju rẹ ko rẹrin, ti ori rẹ pa, ti o si fi awọ kan se asọ rẹ, ti o ni irun nigbogbo ara duro nibẹ pẹlu ọpa kan ni ọwọ kan ati igo ororo ni ọwọ rẹ keji. Oun lo sọ ni ọdun mẹta ati aabọ saaju akoko yii, wi pe, "Iri lasan kò ni sẹ, a fi igba ti mo ba to pe fun un". (O duro ni ipo Ọlọrun, pẹlu awọn nkan bi ọwọn ina lori rẹ, ati awọn ojiji ati nkan bẹẹ ti wọn nsọrọ nipa rẹ). A si ri arugbo ti wọn sọ pe o ti gba-were-mẹsin yi, duro lori oke naa, ti o mu gbogbo awọn eniyan yii wa sibẹ. Kin ni ifamọra yẹn? Ọlọrun ni o setan lati jẹrigbe wolii Rẹ wi pe, o tọ. Ọlọrun ni o n mu isọtẹlẹ sẹ. Ọlọrun tun nkọ itan silẹ, O n mu Ọrọ Rẹ sẹ.

35 Ni nkan bi ọgọrun ọdun melokan si lẹyin eleyii, ọkunrin kan wa ti a fi Ẹmi kan naa kún, o si jade wa lati inu aginju. Oun ko si ni ifọwọsowọpọ pẹlu ẹgbẹ-to-feniyan-sadari kankan, bi o tilẹ jẹ pe, baba rẹ jẹ ẹnikan

ninu ẹgbẹ-to-feniyan-sadari, ti o si jẹ alufaa ninu ilana yẹn. Sugbọn o jade wa lati inu aginju, pẹlu asọ ti a fi awọ aguntan se, ti irun si kun oju rẹ. Dipo ki irun rẹ jẹ awọ eeru, o jẹ dudu. Kin ni ifamọra ọkunrin yii ti o fa gbogbo Jerusalẹmu ati Judea mọra? Awọn kan ninu wọn njade lọ, wọn si n wi pe, "Ọkunrin ẹhanna kan wa ni eti odo lohun yẹn ti o fẹ maa ri awọn eniyan sinu odo. Tani o ti gbọ ohun kan bi iyẹn ri?"

36 Awọn miiran si fẹ mọn nipa rẹ si. Wọn wi pe, "O nilati jẹ pe Mesaya ni eleyi". Ọkan ninu wọn wi pe, "O seese ko jẹ ọkan lara awọn wolii". Wọn ko mọn ohun ti o jẹ gan an. Sugbọn kin ni? Ọlọrun ni O n mu isọtẹlẹ Isaya 40 sẹ, nibi ti O ti wi pe, "Kiyesi" Ohun ti yoo se ni ọjọ ikẹyin, bi Oun yoo se ran iransẹ Rẹ ati ohun ti yoo se.

Nigbanna, a rii lẹyin ọsẹ diẹ si, ọkunrin yi ni idaniloju Isẹ-Ohun-Ọlọrun ti a fi ran-an to bẹẹ ti o wipe, "Ẹnikan wa laarin yin ti o tobi ju mi lọ, emi ko tilẹ lee da bata rẹ gbe. Oun ni yoo si fi Ẹmi Mimọ ati Ina baptisi yin, gẹgẹ bi mo ti fi omi baptisi yin.

37 Ni ọjọ kan, ọdọkunrin kan, ti ko yatọ ni wiwo si gbogbo ọkunrin miiran, ti o jẹ bi ẹni ọgbọn ọdun rin jade wa, a si se itẹbọmi fun Un. Nigba ti Ọkunrin yi si de, ifamọra kan sẹlẹ pẹlu wolii yii, wolii yii se ohun ajeji lọjọ naa. Apejọpọ ko lee salai kiyesi ise wolii naa bi oun se n ba awọn alufaa jiyan ni odikeji odo.

Wọn wi pe, "Ọlọrun lo kọ pẹpẹ yii. Ọlọrun ni O sọ pe ki a se eleyi. Mose ni wolii naa. Awa gba Mose gbọ. A ko lee dẹkun irubọ naa laelae".

Mo lee gbọ bi Johanu se dahun ti o wi pe, "Se ẹyin ko tii ka ninu Iwe Mimọ ohun ti wolii Daniẹli sọ? A oo pa irubọ ojoojumọ ti, yoo dopin" Wakati naa ti de. Se ẹyin ko ti ka ohun ti Isaya sọ ninu ori ogoji? "Ohun ẹnikan ti o n kigbe ninu aginju, pese ọna silẹ fun bibọ Oluwa". Isọtẹlẹ meji ni o wa fun mi. Ohun miiran si tun ni wi pe, se iwọ ko ranti ohun ti wolii Malaki sọ ni irinwo ọdun sẹyin, ni ori kẹta ti o wi pe, "kiyesii, Emi yoo ran ojisẹ Ohun Mi siwaju Mi lati pese ọna de Mi". Se ẹyin ko mọn pe eleyii n mu isọtẹlẹ sẹ ni? A n mu isọtẹlẹ sẹ.

38 Ni akoko naa, wolii yii yiju pada, o si wi pe, "Woo, eyi ni Ọdọ-aguntan Ọlọrun ti O ko ẹsẹ aye lọ!" Bayii, kin ni ifamọra naa? O ti yipada lati wolii si isọtẹlẹ rẹ.

Bayii, kiyesi ohun to sẹlẹ. A ri ọkunrin kan ti O wa bayii, ti ẹnikẹni ko mọn, ọmọ gbẹnagbẹna kan ni. O si rin lọ si eti odo. Nigbati Johanu, wolii nla naa wi pe, mo nilo pe ki Iwọ se iribọmi fun mi, Iwọ si tun tọ mi wa?

O wi pe, "Gba iyẹn laaye bayii, nitori pe, gẹgẹ bii wolii ati Ọrọ naa, o tọ fun wa, lati mu gbogbo Ododo sẹ".

Nitori naa, o loye wi pe, a nilati wẹ irubọ naa ki a to faa kalẹ, o si se itẹbọmi fun Un.

39 Bayii, ifamọra miiran sẹlẹ nigba ti O jade kuro ninu omi naa. Wolii yii, ti o ti jolootọ ni sisọ iran ati akoko rẹ faye, wo oke o si rii ti Ọrun si silẹ, o si ri Ẹmi Ọlọrun bi Adaba ti o sọkalẹ le E lori, ti Ohùn kan si wi pe, "Eyi yi ni Ayanfẹ Ọmọ Mi, Inu Ẹniti Inu Mi dun lati maa gbe". Ọlọrun n jẹrigbe Isẹ iransẹ wolii kan, ohun ti o fa ifamọra ni Jọdani ni yẹn.

40 Arakunrin kan kọrin lẹẹkan, tabi, o yẹ ki o kọrin, "Lori oke to jinna rere, ni agbelebu atijọ ni duro". Kin ni ifamọra ni Ori Oke Kalfari? Nigba ti a rii pe awọn ẹlẹsin aye yii ti da A lẹbi, Ijọba Roomu si ti da A lẹjọ iku …… A si ri I ti a só rọ̀ saarin awọn ọdaran meji, ti orungbẹ ngbẹ Ẹ, ti ẹjẹ si nsan lati ara Rẹ. Nibẹ ni O sorọ si, ti O n kigbe pe, "Ọlọrun Mi, Ọlọrun Mi, eese, ti Iwọ fi kọ Mi silẹ?" Awọn ẹlẹ́sìn si duro nibẹ, wọn n wo O. Wọn ko si mọn wi pe, a n mu isọtẹlẹ Majẹmu Laelae sẹ ni akoko yẹn ni Kalfari.

Dafidi funrarẹ kọ ọ …, o sọrọ ninu Ẹmi, gẹgẹbi gbogbo awọn wolii, o sọ bi ẹni pe oun funra rẹ ni. Dafidi kigbe ninu Orin Dafidi ori keji-le-logun, "Ọlọrun Mi, Ọlọrun Mi, eese ti Iwọ fi kọ Mi silẹ? Gbogbo Egungun mi ni o n wo mi. Wọn lu ọwọ ati ẹsẹ mi". Dafidi sọrọ bi ẹni pe, oun gan ni. Ki I sii se Dafidi, Kristi ninu Dafidi ni.

Ati nibiyii, isọtẹlẹ naa gan ti o ti ẹnu gbogbo awọn wolii jade, ni a nmusẹ ni Oke Kalfari. Kin ni ifamọra ni Oke Kalfari? Ọlọrun ti O n mu Ọrọ Rẹ sẹ.

41 Ifamọra miiran wa lori oke kan, o sẹlẹ ni Pẹntikọsti, nigba ti gbogbo wọn wa nibẹ nibi ase ti ẹsin kan. Wọn ro wi pe awọn ti bori gbogbo awọn to gba-were-mẹsin yẹn. Wọn ko tii gbọ nipa wọn fun ọjọ mẹwa. Lojiji, bi awọn ẹgbẹ oyin, wọn da jade lati ori oke ile naa, wọn si da jade wa si oju popo pẹlu ariwo ati ayọ.

"Kin ni eleyi? Kin ni ifamọra eyi? Se ọtí npa awọn eniyan yii ni?"

Kiyesii, wolii kan si duro laarin wọn. Gẹgẹ bi iwa wolii se gbọdọ jẹ, o wi pe, "Ẹyin ara Israẹli, ati ẹyin to n gbe ni Judea, ati Jerusalẹmu, jẹ ki n sọ eyi di mímọ̀ fun yin, ẹ si tẹti si ọrọ mi. Awọn wọnyi ko mu ọtin yó bi ẹyin se ro. Sugbọn eyi ni ohun naa ti Oluwa sọ nipasẹ wolii Joẹli pe, 'Yoo si se ni ikẹhin ọjọ, Emi yoo tu Ẹmi Mi sori gbogbo eniyan'". Ifamọra naa ni yẹn.

42 Awọn eniyan ẹlẹ́sìn, lẹyin ti wọn ti pa Ọmọ Alade Iye, ati ohun gbogbo, wọn ko ri ileri ti bibọ Ẹmi Mimọ. Ifamọra naa mu ki wọn wi pe, “Tani yii? Kin ni eyi tumọn si? Kin ni o se awọn eniyan wọnyi?”

A a a. Ohun kan naa ni loni. A o o fo ọpọlọpọ ohun ti mo kọ silẹ, ki a lee mu wa si akoko tí a wà yíí. Bakan naa ni o ri loni. Ohun kan naa ni o n sẹlẹ, ibeere kan naa ni wọn n beere, “Kin ni gbogbo ariwo yẹn wa fun? Wo tọtun tosi loju popo: awọn ọkọ ayọkẹlẹ ti awọn arinrin-ajo lati Michigan titi lo̩ de Florida, ati Maine titi lo̩ de California. Lowuro̩ yii, nigba ti mo njade lo̩, tabi ni o̩san, nigba ti a n lo̩ loju popo, iyawo mi ati emi nwo awo̩n no̩mba ara awo̩n o̩ko̩ ayo̩ke̩le̩. Nigba naa ni mo ronu nipa akori iwaasu yii.

“Kin ni eyi tumo̩n si?”

Bi o ti wi ge̩le̩, “Nibikibi ti e̩ran tutu ba wa, ni awo̩n idi yoo korajo̩po̩ si”

43 Mo wi fun iyawo mi pe, “oyin, se o ranti ale̩ ojo̩ naa, ti mo nilati dagbere fun ohun gbogbo to so̩wo̩n fun mi laye yi, ki n si lọ sinu papa lati se ohun ti O̩lo̩run ni ki nse”. Iwọ ko̩ orin ye̩n:

Wo̩n yo wa lati ila oorun ati iwọ re̩,

Wo̩n wa lati ilẹ jijin rere,

Lati ba O̩ba jẹun, gẹgẹbi alejo Re̩

A ti bukun awo̩n atipo yi to!

Wo̩n nwo oju Re̩ Mimo̩

To ndan pe̩lu ife̩ O̩lo̩run

Alabukun, alabapin Ore-o̩fe̩ Re̩

Wo̩n n tan bii wura ninu Ade Re̩.

44 Ohun ti ifamo̩ra naa je̩ niye̩n. Awo̩n iru O̩lo̩run ti a ti yan te̩le̩, ti ko si lee se ohun miiran ju pe, ki wo̩n te̩le E, O se pataki si wa ju iye wa lo̩. Gba e̩mi wa, sugbo̩n mase gba iye̩n. Kin ni ifamọra naa? O̩lo̩run, bi O se maa nse, n mu O̩ro̩ Re̩ sẹ. O n mu o̩ro̩ wolii Sekaraya sẹ le̩e̩kan si.

Nibi ti mo ti ka e̩se̩ ke̩san laipẹ yii, nigba ti Jesu wo̩ inu tẹmpili, tabi ti O wo̩ Jerusalẹmu ti o n gun ke̩te̩ke̩te̩ funfun kekere kan, a mu iso̩te̩lẹ naa se̩ ti Sekaraya wi pe, “Yo̩ gidigidi, iwo̩ o̩mo̩-binrin Sioni. Kigbe soke, iwo̩ o̩mo̩binrin Jerusalẹmu. Kiyesii, O̩ba re̩ nbo̩ wa so̩do̩ re̩; o je̩ olododo, o si ni igbala, pẹlu irẹlẹ, o n gun ke̩te̩kete̩, ati lori ọmo̩ ke̩te̩ke̩te̩”. Ifamora naa niye̩n ni Jerusalẹmu ni olu ipinle̩ e̩sin.

45 Bayii, a ri ìsè̩lè̩ ti opin ojo̩ yii! Je̩ ki a si oju iwe die̩ siwaju ninu Sekaraya, ki a si ri ohun ti o so̩ nipa rè̩. Jẹ ki a sii si ti opin ojo̩ yii. Iye̩n wa fun iran ti arin-gbun-gbun-aye, je̩ ki a a si si ti opin ojo̩ yii. E̩ si si sekaraya, ori ke̩rinla lati e̩sẹ ike̩rin. E̩ si fetisilẹ! A o si ka ipa kan ninu iwe Mimo̩, bi e̩se̩ me̩san, lati e̩se̩ ke̩rin si ike̩san. Fetisile̩ gidigidi. O si je̩ iso̩te̩le̩ bibọ Re̩ ni igbẹyin ojo̩. Fetisile̩ bayii, “Bayi ni Oluwa wi” ni eleyii, Iwe Mimo̩ ni. Sekaraya 14. Ranti Sekaraya 9, ohun ti o so̩? Wo̩n ko si da a mo̩n. Bayii, kin ni o je̩ loni? Sekaraya 14, nso̩ro̩ nipa bibo̩ Re̩.

E̩se̩ re̩ yoo si duro ni ojo̩ naa lori oke-olifi, ti o wa niwaju Jerusalẹmu ni ila oorun, oke olifi yoo si la si meji, si iha ila-oorun ati si iha iwo̩-oorun, afonifoji nlanla yoo wa; idaji oke naa yoo si si iha ariwa, ati idaji re̩ siha guusu.

Ẹyin yoo si sa si afonifoji oke wo̩nni; nitori ti afonifoji oke naa yoo de Asali nitootọ, ẹyin o sa bi e̩ ti sa fun ìsé̩lè̩ ẹ nì ní ojo̩ Ussiah O̩ba Juda…..

46 Ìsé̩lè̩ miiran ti o n se ile aye; Bi iwo̩ba fẹ tẹle imusẹ Iwe Mimo̩ nihinyi, kiyesi e̩se̩ ikarun yii, o sẹlẹ pe, lila ti oke olifi la je̩ nitori ìsé̩lè̩ kan. A si fidi eleyi mule̩ pe̩lu ni Isaiah 29;6 ati iwe ifihan 16;9. Bẹ gege̩ ni. Kin ni? Woli kan naa ti o sọrọ nipa wiwa Rẹ ni igba akọko̩ tun ri wiwa Re̩ le̩e̩keji. Kiyesi, “Bi o ti ri ni ojo̩ ìsé̩lè̩…” Se o ri ohun ti awọn ìsé̩lè̩ naa n se, se o ri isọtẹlẹ wọn “.

OLUWA O̩lo̩run rẹ yoo si wa, ati gbogbo awọn ayanfẹ mimo̩ pe̩lu Re̩.

Yoo si se ni ojo̩ naa, (Halleluya), ni ọjọ naa imole̩ ki yoo mọ, be̩ eni ki yoo sokunkun;

Sugbon yoo je̩ ojo̩ kan, to yoo jẹ mímọ̀ fun OLUWA, ki i se ọsan, ki i se oru; sugbọn yoo se pe, ni asalẹ imọle̩ yoo wa. (O̩lo̩run!).

47 'Imole̩ yoo tan ni igba asale̩“, Wolii kan naa. Awọn eniyan si fọju; ki ni ifamo̩ra naa? Je̩ ki a ka e̩se̩ die̩ si;

Yoo si se ni ọjọ naa, omi iye yoo ti Jerusalẹmu san lọ; idaji wọn sibi okun ila-oorun, ati idaji wọn siha okun èyìn; nigba ẹrun ati nigba otutu ni yoo ri bẹẹ. (Ihinrere ti o n jade lọ sọdọ awọn Juu ati awọn iran alaikọla).

Oluwa yoo si jọba lori gbogbo aye; ni ọjọ naa ni Oluwa kan yoo wa, orukọ Rẹ yoo si jẹ ọkan.

Imọlẹ yoo wa nigba asalẹ. (bee ni)

Iwọ yoo ri ọna si ogo dajudaju,

Ni ọna ti omi, ni imọlẹ ọjọ oni

Ti a sin ọ ni oruko Jesu ọwọn.

Ọdọ ati arugbo, ronupiwada ẹsẹ rẹ,

Dajudaju iwọ yoo gba Ẹmi mimọ.

Imọlẹ irọlẹ aye ti de

Otitọ ni pe, ọkan soso ni Ọlọrun ati Kristi

Se o ri ibi ti a wa?

Awọn orilẹ-ede ntuka, Israẹli n soji

Awọn amin ti awọn wolii ti sọtẹlẹ,

(Pe awọn ìsẹ́lẹ̀ yo wa ninu iran alaikọla lopin ọjọ.

Ọjọ ti iran alaikọla ti fẹ pari, pẹlu ileri idaamu.

Ẹ pada silẹ yin, eyin ti a fọnka tẹlẹ.

Iwọ ti a ti le jade, ti wọn si gbe awọn apoti ẹri wọnyi lori kẹkẹ tuntun, jade kuro nibẹ ki iku to kọlu ọ. Ọlọrun ti fẹsẹ rẹ mulẹ. Yoo si ri bẹẹ.

48 Ẹ jẹ ki a si Iwe Mimọ miiran ninu majẹmu laelae-Malaki, ori kẹrin-ki a si ka ori kẹrin kekere yẹn.

….Kiyesii, ọjọ naa nbọ ti yoo maa jo bi ina ileru; ati gbogbo awọn agberaga, ati gbogbo awọn onisẹ buburu yoo dabi akeku koriko…,

Bayi, eyi ki i se…Malaki 3 ni wiwa Rẹ akọkọ, eyi sini wiwa Rẹ ti o kan. Dokita Scofield paapaa nibiyi, to eleyi tọ. Dajudaju emi ko gba itumọ rẹ gbogbo gbọ, sugbọn, o gbe eleyi kalẹ bi o ti yẹ; isẹ Johanu, ni o wa ni Malaki 3; bibọ Kristi nigba keji ni o wa ni Malaki 4 pẹlu Elijah ti yoo kọkọ wa.

….Gbogbo awọn agberaga ni yoo jo run, ni Oluwa awọn ọmọ Ogun wi, ti ki yoo fi ku gbongbo tabi ẹka kan fun wọn. (Ọrun apaadi "ainipẹkun" da nigbanaa?).

Sugbọn fun ẹyin ti o bẹru Orukọ Mi ni oorun Ododo yoo la pẹlu ipolongo imularada, ti oun ti imularada ni iyẹ apa rẹ. Ẹyin yoo si jade lọ, ẹyin yoo si maa dagba bi awọn ẹgbọrọ maluu ninu agbo.

Ẹyin yoo si tẹ awọn eniyan buburu mọlẹ, nitori wọn yoo jasi eeru labẹ atẹlẹsẹ yin, ni ọjọ naa ti Emi yoo se eyi, ni Oluwa awọn ọmọ ogun wi.

Ẹ ranti ofin Mose iransẹ Mi, eyi ti Mo pa lasẹ fun un ni Horebu fun gbogbo Israẹli pẹlu asẹ ati idajọ wọnni.

49 Bibọ Elijah ni yii.

Woo, Emi yoo ran wolii Elijah si yin.

Iwe Mimọ ti o kẹyin ninu Majẹmu Laelae.

Emi yoo ran wolii Elijah si yin ki ọjọ nlá-ǹlà Oluwa, ati ọjọ ti o ni ẹru to de.

Bayi, iyẹn ko lee jẹ Johanu. Rara. Se o rii, aye kò jó àjórun, ki awọn olododo si rin lori eeru awọn eniyan buburu, se o rii. Rara, rara.

…. Ki ọjọ nlá-nlà Oluwa, ati ọjọ ti o ni ẹ̀rù to de.

Oun yoo si pa ọkan awọn baba dà si ti ọmọ, ati ọkan awọn ọmọ si ti baba wọn, ki emi ki o ma ba a wa fi aye gẹgun.

Kiyesi pipe ti Ẹmi Mimọ, pe Oun ko jẹki bibọ Elijah nigba meji ki o dojuru. Malaki 3 wi pe, "Kiyesii, Emi yo ran ojisẹ Mi siwaju Mi"! Wọn beere nipa Johanu lọwọ Jesu. O wi pe, "Bi ẹ ba lee gbaa, eyi ni ẹni ti awọn wolii wi pe, "Emi yoo ran ojisẹ Mi siwaju Mi. Eyi ni Elijah naa ti yoo kọkọ wa". Malaki 3.

50 Kiyesi bi Iwe Mimọ se kọ ọ silẹ ni pipe. Wo ohun ti eyi jẹ …. Lati fihan awọn ti o fẹ gbagbọ, awọn ti o fẹ ri otitọ. Ranti pe, Jesu danuduro ni agbedemeji Iwe Mimọ kan, nitori pe, a mu apa kan ẹsẹ naa sẹ ni ọjọ naa, eyi ti o ku si wa fun bibọ Rẹ lẹẹkeji? "Lati kede ọdun itẹwọgba Oluwa ati lati se àwòtán awọn onirobinujẹ ọkan," O si danuduro; kii se "lati mu idajọ wa sori awọn keferi" - eyii nì ni bibọ Rẹ lẹẹkeji.

51 Kiyesi bi Iwe Mimọ yi se ba iyẹn mu rẹgi. "Oun, Elijah yoo si yi ọkan awọn baba si ti awọn ọmọ". Bayii, mase da Malaki 4 rú pẹlu Malaki 3. Johanu, Elijah ti o wa saaju bibọ Kristi nigba akọkọ, yi ọkan awọn baba nla ti atijọ si isẹ iransẹ ti awọn ọmọ, isẹ Iransẹ tuntun naa. Kiyesii, "Ati ọkan awọn ọmọ si ti awọn baba". Ninu bibọ Rẹ lẹẹkeji, ni igbẹhin aye, yoo yi ọkan awọn ọmọ si igbagbọ awọn Aposteli lẹẹkan si. Se o ri bi Iwe Mimọ se baramu ni pipe?

Opin Majẹmu laelae ni iyẹn. Majẹmu Laelae. Bayii, a rii wi pe, Imọlẹ wá ni igba asaalẹ. Kin ni gan? Oke tente ni, Ori Oke Tente.

52 Gẹgẹ bi mo ti sọ ni owurọ yii, a ti mu awọn ijọ jade wa nipasẹ awọn ijọ-to-fi-ẹkọkẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun. A ti wa nipa (kii se nipa ọsan gidi, bi mo se sọ lowurọ yii) sugbọn a ti ni ọsan girepu, ọsan tanjarinni ati orisirisi ti a lọ si ori rẹ. Kii se bi o ti ri ni ibẹrẹ rara. Sugbọn lẹyin (ma se alailoye eleyii, ohun niyii). Nigba ti gbogbo awọn ijọ-to-fi-ẹkọkẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun ti pari tan - Wọn ko ni imọlẹ kankan lati ibẹrẹ - ọjọ kan yoo wa, ti a ko lee pe ni ọsan tabi oru.

Kin ni wọn n se? Kin ni wọn n se? Kin ni ọsan lẹmọni nse lori igi ọsan didun? O nlo iye ti igi ọsan gidi, o si n dibajẹ rẹ si ọsan lẹmọni. Ohun ti awọn ijọ-to-fi-ẹkọkẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun se si Ọlọrun ni yẹn. Wọn sọ Ọrọ Ọlọrun di alailagbara nipa asa wọn. "Bayi ni Emi Oluwa wi" niyẹn. Wọn so eso adamọdi - lẹmọni, girepu, - kii se ọsan gidi.

53 Sugbọn kin ni wolii naa sọ? Ọkan naa ti o sọ ninu Iwe Mimọ ti a ka fun alẹ yii - "Ẹ yọ, ẹyin ọmọbinrin Jerusalẹmu, kigbe soke, ọmọbinrin Sioni, nitori Ọba rẹ nbọ sọdọ rẹ, pẹlu iwa tutu ati irẹlẹ, O n bọ lori ọmọ kẹtẹkẹtẹ". Kiyesii, wolii kan naa wipe, "akoko yoo de fun pipọn naa". A maa n ran oorun laye ki o lee mu eso pọ́n. Kin ni idi ti ko fi pọ́n? Ko si eso nibẹ ti yoo mú pọn. Sugbọn iye naa si n tẹsiwaju.

54 O jade wa gẹgẹbi eso girepu lati jẹ ọsan, o si ri pe, o ti di ẹgbẹ-ti-wọn-fi-ọgbọn-eniyan-gbe-kalẹ. Eso girepu ni, kii se ọsan gidi. O tun lọ lẹẹkan si, o si tun wa gẹgẹbi eso lẹmọni. O tun lọ lẹẹkan si, o si tun jade, o jẹ ohun miiran. Ni igbẹyin, ni oke igi naa, o jẹ eso tanjẹlo, tii se ilaji ọsan gidi ati ilaji lẹmọni. Adamọdi, ohun kan ti a ti dibajẹ rẹ. O di idibajẹ ti o si n gbe lati inu iye ti igi naa. Hariha si ni, o fẹrẹẹ le tan ayanfẹ jẹ. O dabi ọsan tootọ, sugbọn kii se ọsan. "Sugbọn Imọlẹ yoo wa," nigba ti o ba dagba kọja ẹgbẹ-ta-fọgbọn-eniyan-gbe-kalẹ ti o si ruwe funra rẹ lẹẹkan si, yoo so ọsan tootọ gẹgẹbi o ti se tẹlẹ ki o to lọ sinu ilẹ. Nigba naa imọlẹ yoo wa!

Kin ni ifamọra yii, kin ni o n sẹlẹ yii? O n mu Ọrọ Ọlọrun sẹ! Awọn ajẹri meji lo wa ninu Majẹmu Laelae pe eyi yoo sẹlẹ.

55 Ẹ jẹ ki a mu Ihinrere ti Johanu 14:12 lati inu Majẹmu titun; Jesu wi pe, "Ẹni ti o ba gbagbọ ninu Mi, isẹ ti Emi n se ni oun naa yoo se pẹlu.

Bẹẹ pẹlu, ni Luku 17:22 si 30, O wi pe, "Bi o ti se ri ni ọjọ Lọti, ki a to jo Sodomu run, bẹẹ ni yoo ri ni ipadabọ Ọmọ eniyan naa, lọjọ naa ti a oo fi Ọmọ eniyan han".

Iwọ saa wo awọn Iwe Mimọ! "Ọmọ Eniyan naa", Jesu Kristi, ọkan naa lana ati titi lae, O ti dagba kọja awọn ijọ-to-fẹkọkẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun, o si ti dagba de tente ori igi naa. Ohun ni O sọ ni Ihinrere ti Johanu 14 tabi 15? "Gbogbo ẹka ti o wa ninu Mi ti ko ba so eso naa, a oo gee lulẹ, a oo si sọọ sinu ina, a oo joo run. Sugbọn gbogbo ẹka ti o ba so eso, a oo fọọ mọn".

56 Ah, ojo àkọ́rọ̀ ati ojo àrọ̀kúrò tootọ yoo wa ni opin ọjọ lori ẹgbẹ kekere ti yoo wa pẹlu Rẹ lori kẹtẹkẹtẹ kekere yii, pẹlu ọkan tutu ati irẹlẹ, ko si ni ohun kan to fi jọ ifi-ẹkọkẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun, wọn yoo maa ke, "Hosanna si Ọba ti nbọ wa, ni Orukọ Oluwa!" Kin ni o sẹlẹ loni? Kin ni ifamọra lori oke naa?

57 Laipẹ pupọ sẹyin, mo duro nibi aga iwaasu yii, mo si sọ nipa Ẹmi Mimọ pe, "Ọjọ naa nbọ, nigba ti wọn yoo gbá èèkàn kan mọlẹ niwaju ile rẹ, wọn yoo si wú ẹnu bodè ile rẹ, ki iwọ ki o lee ré eleyi fo, ki iwọ ma si

se binu”. Mo si ri ẹnu-bode ile mi, ti wọn si wu u danu ti o si wa ni ilẹ ẹba oke kan. Mo ri oke to wa niwaju ile mi ti wọn wuu, pẹlu awọn pako ati ohun miiran ti wọn wó papọ sibẹ. Mo wo o, mo si ri ọmọ alẹja kan ti o wu ẹnu ibode ile mi naa. Mo wi pe, “Kin ni o de, ti o ko fi sọ fun mi?” O si gbiyanju lati bami ja, mo si nilati luu. Nigba ti eyi si sẹlẹ, mo wi pe, “Emi ko tii se eleyi lẹyin igba ti mo dẹkun fifi-ija-pawo ninu gbagede, sugbọn mo kan fẹ ki o mọn”. Mo si gba a ni ẹ̀sẹ́ kan. Nigba ti mo si gbe e sanlẹ, mo faa dide, mo tun luu bolẹ lẹẹkan si, mo si luu bolẹ ni igba mẹta tabi mẹrin, lẹhin naa, mo taari rẹ si ẹyin oke naa. Nigba naa, ni mo lọ si ibi to wa, mo wi pe, “Iyẹn ko tọ”. Mo si faa dide, mo bọọ lọwọ, mo wi pe, “Inu ko bi mi si ọ, sugbọn mo saa fẹ ki o mọn pe, iwọ ko lee bami sọrọ bẹyẹn”. Nigba ti mo si yiju pada ti mo pada wa, Ẹmi Mimọ duro si ẹnubode mi, O wi pe “Bayii, ré iyẹn kọja. Nigba ti wọn ba kan èèkàn yẹn mọlẹ, lọ si Ìwọ̀ oorun.

Iwe yii, ni ohun gbogbo ti mo nilo

Iwe yii ni olutọsọna rere (ohun ti o n fihan

Ọna lati lọ yipo idamu mi) Amin. Iwe naa si ni Ọrọ naa, Ọrọ naa si ni Ọlọrun. Re idamu rẹ kọja. Yoo sọ fun ọ ohun ti iwọ yoo se.

58 Ni ọdun mẹta sẹyin, mo gbọ ti ọrẹ mi kan ti o jẹ wọnlẹ-wọnlẹ, osisẹ ijọba ilu yii, o n gbe isalẹ opopo ile mi, o si kan èèkàn kan mọlẹ. Mo lọ baa, mo wi pe, “Kin ni o sẹlẹ Mud?” Ọmọ Ọgbẹni King ni, ọrẹ mi ni.

O wi pe, “Billy, wọn yoo fẹ titi yi sẹyin”

Gbogbo yin ranti. Mo wi pe, “O lee jẹ iran yẹn ni”. Mo sọ fun Arakunrin Wood, mo wi pe, “Tọju ilẹ rẹ. O seese ki afara odo yẹn gba ibiyi wa, tabi ohun kan”. Wọn tu titi naa ka, okuta biriki si fọnka si gbogbo ilẹ. Nitori naa, mo sọ fun un pe, “Tọju ilẹ rẹ”.

Nigba ti Ọgbẹni King si sọ fun mi pe iyẹn yoo sẹlẹ, mo wọle lọ, mo si wi fun iyawo mi to joko nibẹ yẹn pe, “Oyin, ohun kan wa ti a kọ nipa iyẹn. ”Bayi ni Oluwa wi“ ni níbìkan.

59 Mo wọle lọ, mo si mu iwe mi, mo wo inu rẹ, o si wi pe, “Yoo si sẹlẹ pe …” Lẹyin ọdun mẹjọ!

Nigba ti mo si wo o, mo wi pe, “Asiko ti to bayi, oyin, a gbọdọ lọ si Iwọ oorun”.

Ọjọ meji lẹyin eleyi, mo duro ninu iyara ni nkan bi agogo mẹwa owurọ, mo wọ inu Ẹmi Ọlọrun, mo si ri awọn ẹyẹ adaba diẹ ti wọn nfo papọ yẹn, mo wo awọn ẹyẹ kekere naa. Ẹ ranti rẹ. Mo ri awọn Angẹli Meje ti wọn to bi ile alaramọnda to kere loke to si fẹ ni isalẹ, wọn sare wa si ọdọ mi, wọn wi pe, “Lọ si Iwọ oorun, lọ si Tucson, ki o si wa ni ogoji ibusọ si iha ariwa mọ ila oorun Tucson. Iwọ yoo si maa yọ èèmọ́ (ẹmimọ) kuro lara asọ rẹ”.

60 Arakunrin Fred Sothman, ti o joko nibẹ yẹn, ti o n wo mi bayii, wa nibẹ ni owurọ ọjọ naa. Emi si ti gbagbe nipa rẹ.

Mo wi pe, “Ìró nla kan dun bi ìsẹ́lẹ̀ ti o mi gbogbo agbegbe naa. Emi ko ri bi eniyan kan se lee rú là”. Ẹru ba mi. Mo duro ni Phoenix; gbogbo ẹyin ti o ngbọ mi lalẹ yii, ẹ jẹri mi. Mo waasu, “Ẹyin Alagba, Akoko Wo Niyii?” Nibo ni a wa? Mo lọ si Iwọ oorun orilẹ ede yii. Ọpọlọpọ yin lo ni ohùn ta gba silẹ naa. Pupọ yin ni ẹ gbọ ti a sọ ọ bi ọdun kan tabi ju bẹẹ lọ ki o to sẹlẹ.

61 Mo lọ si Iwọ oorun, mo n fọkan daniyan nipa ohun ti yoo sẹlẹ. Lọjọ kan, mo gba ipe kan lati ọdọ Oluwa. Mo sọ fun iyawo mi pe, “Oyin, boya isẹ mi ti pari”. Emi ko mọn. Mo wi pe, “O seese ki o jẹ wi pe, Ọlọrun ti pari pẹlu mi, boya emi yoo ma lọ si Ile mi Ọrun. Lọ duro pẹlu Billy, pẹlu awọn ọmọ, Ọlọrun yoo la ọna fun ọ, lọnakọna. Gbe igbe aye ti o tọ pẹlu Ọlọrun. Ki o rii pe awọn ọmọ pari ile iwe wọn, tọ wọn dagba ninu imọn Ọlọrun”.

O wi pe, “Billy, iwọ ko mọn boya eyi ri bẹẹ”.

Mo wi pe, “Rara. Sugbọn, ko si eniyan ti o lee la ninu ohun to sẹlẹ yẹn”.

Ni owurọ ọjọ kan, Oluwa ji mi dide. O wi pe, “jade lọ si oke Sabino Canyon”. Mo mu iwe kekere kan ati Bibeli mi. Iyawo mi wi pe, “Nibo ni o n lọ?”

Mo wi pe, “Emi ko mọn. Emi yoo sọ fun ọ bi mo ba de”.

62 Mo goke lọ sori apata lọ si ibi ti awọn idi ti nfo kaakiri. Mo n wo agbọnrin kan to duro sibẹ. Mo kunlẹ lati gbadura, mo si gbe ọwọ mi mejeeji soke, ida kan si bọ si ọwọ mi. Mo wò kaakiri, mo ro o wi pe, “Kin ni iyẹn? Kii se pe, emi ko mọn ohun ti mo nse. Ida yẹn niyii lọwọ mi, o mọn, o ndan, o nkọ yinrin ninu oorun”. Mo wi pe, “Bayii, ko si awọn eniyan ni ọpọlọpọ ibusọ ni ibi yii ni ori oke yii. Nibo ni eleyi ti wa?”

Mo gbọ ti Ohùn kan wi pe, “Ida Ọba Naa ni Iyẹn”.

Mo wi pe, “Ọba kan a maa fi eniyan kan jẹ balogun nipa ida”.

Ohùn naa tun pada wi pe, “Kii se Ida ọba kan, Sugbọn Ida Ọba Naa ni, Ọrọ Oluwa”. O wi pe, “Ma bẹru, onfa kẹta saa ni. O jẹ ijẹrigbe isẹ iransẹ rẹ”.

63 Mo lọ se ọdẹ pẹlu ọrẹ mi kan, lai mọ ohun ti yoo sẹlẹ. Ẹnikan si pe mi, ẹni ti o tako mi nipa aworan Angẹli Oluwa yẹn, ti o ya aworan naa. Mo ni lati lọ si Houston nipa ọmọ rẹ, nitori wọn ti dajọ iku fun un, wọn yoo si paa lẹyin ọjọ diẹ si. O si pade mi nibẹ, o fọwọ mejeeji gba mi mu mọra, o wi pe, “Tilẹ roo wo pe, ọkunrin ti mo tako gan an, ni o wa lati gba ọmọkunrin mi kan soso!” Ẹgbẹ to nse aanu ọmọniyan fun mi ni ohun kan ti wọn pe ni Oscar, eyi si fun mi laaye lati gba eniyan kan lọwọ iku, bi a ba ti dajọ iku fun un.

64 Lẹhin naa, a pada. Mo lọ si ori oke lati lọ sọdẹ. Nibẹ, Arakunrin Fred ati emi jade lọ ni owurọ ọjọ kan - emi ti pa ẹlẹdẹ igbo temi - Mo si woo, mo ri ibiti awọn ẹranko naa lọ. Mo wi pe, Arakunrin Fred, lọ si ori oke yẹn ni kutukutu owurọ, emi yoo si bọ si ori oke keji. Emi ko ni ta awọn ẹranko naa nibọn, Sugbọn emi yoo ta ibọn siwaju wọn lati le wọn pada si ọ bi wọn ba wa si ọdọ mi.

65 Arakunrin Fred lọ si ibẹ, ko si si awọn ẹlẹdẹ kankan nibẹ. O juwọ simi, mo si rii. Mo sọkalẹ si koto inu canyon naa, afonifoji nla kan. Oorun sẹsẹ bẹrẹ sii yọ ni. Mo yipo gba odikeji oke naa, emi ko si ronu nipa isọtẹlẹ naa. Mo joko, mo n simi, Mo si roo pe, “kin ni o sẹlẹ si awọn ẹlẹdẹ igbo yẹn?'

Mo joko bi awọn India se maa n joko, se ẹ mọn, mo dabu ẹsẹ mi; mo si wo ara sokoto mi, mo ri èmìmọ́ kan. Mo mu u kuro, mo si wi pe, “Iyẹn sajeji; Ibi yii ni mo wa, ni ogoji ibusọ, ni ila oorun, ariwa Tucson. Ọmọkunrin mi kekere Joseph niyẹn to joko demi” Bi mo se dide lati wo o, mo ri ọ̀wọ́ awọn ẹlẹdẹ yẹn jade ni nkan bii ẹgbẹrun yaadi si ibi ti mo wa. Mo ju èmìmọ́ naa silẹ. Mo wi pe “Emi yoo da awọn ẹranko yii. Emi yoo lọ pe Arakunrin Fred, emi yoo si so iwe kekere kan lati jẹ ki o mọn ibi ti yoo gba lati lee ri awọn ẹranko naa. A o si pe Arakunrin Fred.'

Mo si bẹrẹ si sare ni ori-oke naa, bi mo se lee sare to ni odi keji. Lojiji; mo ro wi pe ẹni kan ti ta mi ni ibọn ni. Emi ko tii gbọ iro ti o to yẹn ri. O mi gbogbo adugbo naa. Nigba ti mo si gbọ iro naa, Awọn Angẹli meje duro niwaju mi, Awọn mejeeje duro papọ.

66 Mo pade Arakunrin Fred ati awọn to ku nigba ti o se diẹ si, Wọn wi pe, “kin ni yẹn”? Mo wi pe, “Oun ni yẹn”.

“Kin ni iwọ yoo se?”

“Emi yoo pada sile. Nitori pe,” “Bayii ni Oluwa wi”, awọn ohun ijinlẹ meje ti a ti fi pamọ sinu Bibeli ni gbogbo ọdun wọnyi, awọn ijọ-tofi-ẹkọkẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọrọrun wọnyi ati ohun gbogbo bẹẹ, Ọlọrun yoo si awọn ijinlẹ meje naa fun wa ninu awọn edidi meje“.

Obiripo yẹn si dide lati ilẹ bii ikuuku ti o dijọ. Nigba ti O si se bẹẹ tan, O goke lọ titi ti O fi ga kọja awọn oke yẹn. O bẹrẹ sii lọ si iha iwọ oorun lati ibi ti O ti wa. Awọn onimọn-ijinlẹ, ri I nigba ti o se, O ga si ilẹ ni iwọn ogbọn ibusọ, O si fẹ ni iwọn ibusọ marun-dogbọn, O si wa ni obiripo ti ile alara-mọda to fẹ ni isalẹ, ti o si kere ni oke.

67 Ni ijelo, mo duro nibẹ, mo yi aworan naa si ọwọ ọtun, mo si ri I pe, Jesu gẹgẹbi O se wa ninu awọn igba Ijọ Meje, ti O ni ibori funfun ti o fihan wi pe, Oun ni Ọlọrun Olodumare, Alasẹ-ti-O-ga-julọ. Oun ni Alfa ati Omega, Oun ni Ẹni ibẹrẹ ati Ẹni opin; Oun ni Onidajọ-Alasẹ-Togajulọ ni gbogbo ainipẹkun, ti O duro nibẹ, ti O si nfi ẹsẹ Isẹ iransẹ wakati yi mulẹ. Imọlẹ yoo si wa ni igba asalẹ; kin ni gbogbo rẹ tumọn si? Kin ni o jẹ?

68 Mo lọ si Iwọ oorun. Lori oke yi kan naa pẹlu Banks Wood nibẹ. O wi pe, “Ju okuta kan soke. Sọ fun ogbẹni Wood pe, 'Bayii ni Oluwa wi, iwọ yoo ri ogo Ọlọrun.'”

Ni ojọ keji, mo duro nibẹ, Iji kan sọkalẹ wa, o si fọ́ oke naa ka. Awọn okuta si ge ori gbogbo igi to wa nibẹ kuro bii ẹsẹ bata mẹta si mẹrin ni ikọja ori mi soke. O si se iro nla mẹta, awọn ará naa sare wa si ọdọ mi. Awọn ọkunrin bi marun-dogun ti o wa nibẹ , ti ọpọ wọn si jẹ oniwaasu ati bẹẹbẹẹ lọ. “Kin ni iyẹn?” O wi pe, “kin ni eleyi”?

Mo wi pe, “Idajọ nkọlu bebe okun Iwọ Oorun”.

69 Ni nkan bi ojọ meji lẹyin eleyi, ìsẹ́lẹ̀ kan fẹrẹẹ ri Alaska, kin ni Imọlẹ yẹn ni ori oke Sunset ni igbo colorado ni Arizona? Kin ni ohun ajeji to sẹlẹ nibẹ ti o mu ki awọn eniyan maa wakọ lọ sibẹ lati ila oorun, ati iwọ oorun, ki wọn maa sa okuta to tuka naa nitori ti iji yẹn kọlu, ti olukuluku awọn okuta naa si ni igun mẹta mẹta. (ọkan ni awọn apele mẹta na). Awọn okuta wọnyi si wa lori tabili ati osuwọn ti o n wọn bi nkan se wuwo si kaakiri

orilẹ-ede yii bayii - kin ni ohun ajeji yii to sẹlẹ lori oke sunset ni igbo Coronado.

70 Junior Jackson ti o ngbọ mi bayii, se ẹ ranti ala ti o la, ti mo tumọn, nibi ti mo ti nlọ si apa iwọ oorun". Ìsèlè yii si sẹlẹ ni ori oke sunset (oke Iwọ oorun). Akoko irọlẹ ni. Isẹ iransẹ ti irọlẹ ni akoko ti oorun n wọ, ti igbekalẹ isọtẹlẹ si ndi mimusẹ. Imọlẹ yoo si wa ni akoko irọlẹ, lori oke iwọ oorun, ninu igbo Coronado, ni ogoji ibusọ lapa ariwa si Tucson. Iwọ gbe iwe aworan ti nfi ipo gbogbo ilu ati ilẹ han lori ilẹ aye, ki o si wo ibi ti o ga julọ lori oke Sunset. Ibẹ gan ni o ti sẹlẹ. N ko mọ tẹlẹ, titi di ijelo.

71 Ni ọna gbogbo, iyẹn ko lee ku. O sa tunbọ nsi ara Rẹ paya ni. Bẹrẹ lati isẹlẹ na gan ti o sẹlẹ, si awọn aworan Rẹ ti wọn ya, tii se Jesu ti O nwo wa, titi mọn bi o se jẹ pe oke Sunset ni o ti sẹlẹ, ni Imọlẹ asaalẹ ti tan. Imọlẹ asaalẹ ti de. Ọlọrun n jẹrigbe Ara Rẹ. Kin ni? Otitọ ni pe Ọlọrun ati Kristi jẹ ọkan soso. Awọn melo lo ri Ibori funfun naa ni ori Rẹ bi a ti sọ ọ ni Iwe ifihan:1? Se o rii, Ọlọrun Olodumare, Ẹni ti o ni gbogbo Asẹ ati Agbara; ko si ohun miiran, ko si Ọlọrun miiran, ko si ohun kankan mọn. "Ninu Rẹ, ni ẹkunrẹrẹ Ọlọrun ngbe ni iduro" Awọn Angẹli funrawọn ni ibori Rẹ. Aamin.

72 Kin ni o sẹlẹ ni ori oke sunset? Ọlọrun n fẹsẹ Ọrọ Rẹ mule, pe otitọ ni. Ohun ti o fa gbogbo ariwo wọnyi niyẹn. Kiyesii, Ọlọrun ni O n mu Ọrọ Ileri Rẹ sẹ leẹkansi, ti Iwe Ifihan 10:1-7. "Ati ni ọjọ ohun isẹ iranse ti Angẹli keje, a o pari gbogbo ijinlẹ Ọlọrun. Awọn ohun ijinlẹ ti Iwe Ifihan 10:1-7, isẹ iransẹ to kẹyin si ijọ to kẹyin. Eyi mu Iwe Luku 17:30 sẹ ni iran yi "Ni ọjọ naa ti a o fi Ọmọ Eniyan Naa han".

"Awọn eke wolii ati eke Kristi yoo si dide, wọn yoo se isẹ amin ati isẹ ara nla, nla to bẹẹ gẹ ti yoo fi tan awọn ayanfẹ jẹ, kani o seese". Awọn eniyan si wa ni iyemeji sibẹ. Ati bi o se maa n sẹlẹ, o n se ijọ pẹlu ni kayeefi.

73 Awọn onimọn ijinlẹ sibẹ, ni gbogbo Tucson, wọn n kọwe nipa rè sinu iwe iroyin. Titi pada lọ de ori oke Lemmon, awọn ẹrọ ayaworan nla yẹ ko rii bi O se dide lati ibi ti a duro si, ti O si nlọ ninu ofurufu si apa iwọ oorun, ti o n fihan pe, akoko ti dopin. Ko lee lọ pupọ si mọ́ nibẹ, o ti de bebe okun ti Iwọ Oorun. Idajọ kọlu aye ni apa ibi ti o gbalọ. O kọja lọ lori Phoenix ati lori Prescott, O si kọja lori awọn oke lọ si bebe okun Iwọ Oorun. Wọn si lọ soke si…… Nibo ni wọn lọ? Taara lọ si Alaska, ìsẹ́lè si n san bi àra, o nlọ ni apa ibi ti O gba lọ.

74 Ile isẹ ti-nfi-imọn-ijinlẹ wo ofurufu ti o wa ni Tucson ati gbogbo awọn to wa nilu naa si n beere sibẹ, awọn oluwadi-nipa-imọn-Ijinlẹ si nse iwadi, wọn n gbiyanju lati mọn ohun to jẹ gan an. O ga de ibi ti ikuukuu ojo ko lee de. "Kin ni o se e? Ohun na da?" O si nse wọn ni kayeefi bi Imọlẹ nipa agbara nla Ọlọrun ni ofurufu naa se farahan, gẹgẹbi awọn amoye se wa si Jerusalẹmu nipa irawọ ti wọn tẹlẹ, ti wọn si n sọ wi pe,"Ẹni naa ti a bi ni Ọba awọn Juu da?". Kin ni o sẹlẹ? Ọlọrun ni O n mu Ọrọ Rẹ sẹ. "Irawọ kan yoo si dide lati inu Jakọbu wa".

75 Ọlọrun Ọrun si seleri pe, akoko asaalẹ yoo ni Imọlẹ asaalẹ. Ni ọdun mẹta sẹyin, ijinlẹ yii jẹ isọtẹlẹ, "Akoko wo ni yii, Alagba? Sugbọn bayii, o ti di itan, o ti koja. A ti mu ileri naa sẹ. Akoko wo niyii, alagba ati kin ni Ifamọra naa? Ọlọrun ni o n mu Ọrọ Rẹ sẹ: Ọkan naa ni Oun, lana, loni ati titi lae.

Ejẹ ki a gbadura.

76 Ọlọrun wa ọwọn, mo ti da awọn eniyan naa duro pẹ, o tilẹ pẹ ju bi mo se lero lọ. Mo gbadura Ọlọrun, pe a ti sọ ohun kan, tabi se ohun kan ti yoo jẹ ki awọn eniyan nibi gbogbo ni oye. Ati nipa riri, ati nini oye, ki wọn lee gbagbọ wi pe, iwọ ni Kristi tootọ ati Ọrọ ti a n fẹsẹ rẹ mulẹ jẹ ifẹsẹmulẹ pe, Ọrọ naa pé, a si n mu U sẹ ni akoko Rẹ.

Bayii, Jesu Oluwa, Iwọ sọ ninu Ọrọ Rẹ pe, aye yoo wa ni ipo Sodomu. A mọn iyẹn, a si lee wo o. O si sọ wi pe, bi o ti ri ni ojọ naa, ti a ran Ojisẹ mẹta si awọn alaikọla ati awọn Heberu. Ọkan ninu wọn si jẹ Ọlọrun funra Rẹ, Ọmọ Eniyan Naa, ti a fihan ni irisi eniyan, ti O si se isẹ iyanu kan, to bẹẹ ti O sọ fun Abrahamu ohun ti Sarah n se leyin Rẹ ninu agọ. O sọ pe, eyi yoo tun sẹlẹ leẹkan sii nigba ti iran alaikọla yoo wa ni ipo Sodomu. A si ti de ibẹ Oluwa. Awọn isọtẹlẹ miiran si n fẹsẹ ohun kan naa mulẹ, ti rírán Elijah ni opin ojọ, ẹmi Elijah lori ilẹ aye lati yi ọkan awọn ọmọ pada si ti awọn baba. Mo si gbadura, Ọlọrun, pe ki o fẹsẹ Ọrọ Rẹ mulẹ ni wakati yii, ati pe, Iwọ jẹ ọkan naa lana, loni ati titi lae. Se eyi fun wa, Baba. Tirẹ ni gbogbo wọn. Mo gbadura pe ki O fun wa ni awọn ibukun wọnyi, ki o si jẹrigbe ohun ti a ti sọ, fun Ogo Ọlọrun ni orukọ Jesu Kristi. Aamin.

77 Eniyan lee sọ ọrọ kan, Ọlọrun ni o lee fi ẹsẹ rẹ mulẹ pe, otitọ ni. Ohun kan ni lati sọ ohun kan, ohun miiran ni ki Ọlọrun se e. Ọlọrun ko nilo olutumọ kankan. Oun ni o ntumọn Ọrọ Rẹ funra Rẹ.

Bayii, nipa ifẹ Ọlọrun, a ti n gbara di lati gba adura fun awọn alaisan bi a o ti pe wọn sori ila fun adura. A si mọn pe, ko si ẹnikan, iba jẹ ọkunrin ni, obinrin, eniyan kan tabi angẹli ti o lee wonisàn, nitori pe, Ọlọrun ti see na. O ti pese silẹ fun, ohun kan soso ti o nilati se ni ki o gba a.

78 Ko si eniyan kan, tabi angẹli, tabi ohunkohun titi kan Ọlọrun funra Rẹ, ti o lee dari ẹsẹ rẹ ji ọ. A ti se e na. Jesu ti se iyẹn ni ori agbelebu. Sugbọn ko ni se ọ ni ire kan afi igba ti o ba to gba a, se e ori.

Ohun kan soso ti a lee se, ni ilana ti Ọlọrun ti fun awọn onigbagbọ lati gbe ọwọ le alaisan. Wọn ti se eyi ni gbogbo iran, ni gbogbo isọji. Wọn si pe e ni Ọlọrun.

79 Abrahamu ri ọpọlọpọ awọn amin. Sugbọn akoko kan de, ti Abrahamu ri amin rẹ ti o gbeyin ki Sodomu to jona; eyi si ni Ọlọrun ti o fi ara Rẹ han gẹgẹ bi eniyan. Se o gba iyẹn gbọ bi? Njẹ Jesu sọ pe yoo sẹlẹ lẹẹkan si bi?

80 Bayii, awọn melo nibi, ati ni gbogbo ibi ti ẹrọ ibanisọrọ kaakiri orilẹ-ede gbe ọrọ yi de, bi ẹ ba si n fetisilẹ, ẹ gbaradi bayi fun adura, ẹ bẹrẹ sii gbadura. Ẹyin ti ẹ si ni asọ ìnujú nihin. Bayii, emi ko lee sọ fun Ọlọrun ohun ti yoo se. Rara. Ki a ma ri, pe emi yoo tilẹ gbiyanju rẹ̀. Aseyi-O-wu ni. O maa nse ohun to ba fẹ se. Mo kan lee gbọran sii lẹnu ni, ki nsi sọ ohun ti o ba sọ.

81 Bayii, awọn eniyan na duro kaakiri ni ẹgbẹ ogiri, wọn kun gbogbo ile ni akunfaya. Mo tilẹ ro o wo boya a lee bere lọwọ Ọlọrun bayii wi pe, “kin ni ifamọra yii? Bi Ọlọrun yoo ba tun sisẹ agbara nla laarin wa lẹẹkan si (awọn alejo le wa nibi), bi O ba tun sisẹ agbara laarin wa, ki O si fi oju Olubukun Rẹ han laarin wa, ki O fihan pe, Ẹmi Rẹ wa nibi, ki O si fihan pe Oun jẹ ọkan naa lana, loni ati titi lae, njẹ olukuluku wa (lẹhin awọn iwaasu meji to lagbara yii) lee gbagbọ pe bẹẹ ni O ri. Se iwọ lee se eleyi? O dara.

82 Dipo ki emi ki o pe awọn eniyan wa si ori ila fun adura nigba naa, pẹlu bi ibi yii se gbona nitori ọpọ ero ti a funmọra, ti a si kun gbogbo ẹgbẹ ogiri. Mo wo yika lati pe awọn eniyan wa si ori ila fun adura, ko si seese. Wo o bi wọn ti duro nibẹ yẹn. Se mo lee se ni ọna yii bi? Awọn alaisan, akete aisan, ati ohun gbogbo bẹẹ ti o kun ile, o ko lee se e. Nitori bi iwọ ba ni kaadi adura lọwọ, diimu, yoo sisẹ. A o o kan ọ bi iwọ ba fẹ wa si ori ila fun adura. Sugbọn, ko di didan fun ọ lati wa si ori ila fun adura.

83 Ọgbẹni Shepherd ni alẹ ọjọ aiku to koja ko wa si ori ila adura kankan. Mi o ro wi pe o tilẹ ni kaadi adura rara. Njẹ ọgbẹni Shepherd wa nibi lalẹ yii? Oun da? Se o wa nibi? O wa ni ẹyin. Ọgbẹni Shepherd, njẹ iwọ ni kaadi adura ni ọjọ yẹn bi? Iwọ ko ni? Oun ko ni. O joko ni ibi kan naa lalẹ yii. Ibi ti o dara lati wa niyẹn Ọgbẹni Shepherd.

84 Kii se pe o nilati wa nibẹ nikan, sugbọn saa ni igbagbọ. Nitori ranti, obinrin kekere kan fi ọwọ kan isẹti asọ Rẹ, Oun si ni imọnlara rẹ. Oun si jẹ ọkan naa lana, loni, ati titi lae. Iwe Heberu ninu Majẹmu titun sọ wi pe, Oun ni Olu Alufaa ni asaalẹ yii, ti a lee fi imọnlara ailera wa kan. Se o gba iyẹn gbọ? Ni igbagbọ nigba naa. Ma siyemeji. Gba a gbọ, yoo si wa si imusẹ. Iwọ lee ni ohun ti iwọ beere fun, bi iwọ ba lee gba gbọ. Sugbọn o nilati gbagbọ. Se iwọ yoo gba gbọ? Se gbogbo yin yoo gba a gbọ? Awọn melo ni yoo gbagbọ bayii? Ki Ọlọrun bukun yin.

Emi ko mọn ẹni ti ẹ jẹ. Emi ko mọn eyikeyi ninu yin. Kii se ojuse mi lati mọ eyikeyi ninu yin. Ojuse Ọlọrun ni lati mọ nkan wọnyi. Sugbọn Oun yoo se bi iwọ ba lee gbagbọ. Se iwọ yoo gbagbọ bayii?

85 Bayii Ọlọrun Ọwọn, dajudaju, awa kii se awọn ẹgbẹ adamọdi Kristẹni- a ko gbọdọ jẹ bẹẹ - ẹnikan ti a nilati maa kẹ gẹgẹ bi ọmọ ọwọ. Iwọ ko ni iru awọn eniyan bẹẹ Oluwa. Iwọ ni awọn onigbagbọ takuntakun. Iwalaaye Isọkalẹ Ọlọrun gan-an nmu ọkan eniyan gbina. Gẹgẹbi Abrahamu se gba Ọlọrun gbọ. O sọ ara Rẹ di mimọ fun un. Lẹhinnaa, O fi ara Rẹ han fun un, O si se amin kan, oun si gba O gbọ. Iwọ pa ara rẹ da si ti ọdọkunrin, ati iyawo rẹ pẹlu, ti iyawo rẹ si jẹ apakan ara rẹ. Nigba naa ni ọmọ tuntun naa jade wa, ọmọkunrin ti a seleri naa.

86 Ọlọrun, Iwọ se ileri pe, gẹgẹ bẹẹ ni yoo ri ni ọjọ oni. Mo gbadura pe ki o fẹsẹ Ọrọ yii mulẹ. A o si mu ileri yẹn kanna sẹ ti o wi pe, bi o ti ri ni Sodomu, ni yoo ri lọjọ oni, ki a to jo Sodomu run, tii se iran alaikọla nigba naa, ki idajọ to kọlu u. Nitori naa, idajọ ko nii pẹ kọlu gbogbo orilẹ ede alaikọla, awọn Juu si ni ọdun mẹta ati abọ ni akoko ipọnju nla, wahala Jakọbu, tii se itẹsiwaju aadọrin ọsẹ Dạnieli. Sugbọn akoko ti a yan fun iran alaikọla ti buse, o ti to akoko lati lọ. Iwọ si fun un ni amin yẹn, O si sọ pe, yoo sẹle lẹẹkansi. Fi fun wa Ọlọrun. Awa wa ni ọwọ Rẹ, se si wa bi o ba ti tọ loju Rẹ. Ni Orukọ Jesu. Amin.

87 Bayii, mase ni aibalẹ ara. Bawo ni yoo se ri, bi ara mi ko ba balẹ. Bayii, emi nse ohun kan nihin ti o nilati gbẹkẹle iseyiowu Ọlọrun. Sugbọn kin ni idi ti emi fi se eyi? O sọ pe, yoo ri bẹẹ. Ọrọ na pari. Bi Oun ba si funra Rẹ fẹsẹ Ọrọ na mulẹ niwaju yin, se iwọ ko ni lee gbagbọ ninu Rẹ ni? Dajudaju. Iwọ saa ni igbagbọ bayii, ki o si gba A gbọ. Jẹ ki emi saa wo kaakiri, ki n wo ibiti Ẹmi Mimọ yoo dari si, ati ohun ti yoo se. Ọwọ Rẹ ni iyẹn wa. Sugbọn bi iwọ ba saa ni igbagbọ, saa ti gbagbọ, ohun gbogbo lo seese fun awọn ti o gbagbọ. Gbogbo yin, ti ẹ gba iyẹn gbọ, ẹ nawọ soke ki o si wi pe, “Emi gba a gbọ” (Ipejọpọ wi pe, “Emi gba a gbọ”) Mo gba A gbọ pẹlu gbogbo ọkan mi.

88 Bayii, mẹta yoo jẹ ifẹsẹmulẹ, bi Oun ba see nigba mẹta lera wọn lati fihan pe otitọ ni. Emi ko fẹ mọn ibiti

iwọ wa, tabi ẹni ti iwọ ise, saa ni igbagbọ, ki o si gbagbọ. Bayii ẹ má rìn kaa kiri.

Arabinrin ti o n gbadura, emi ko mọn ọ. Saa joko nibiti iwọ wa. Iwọ ko nilo lati wa. Emi ko mọn ọ, sugbọn iwọ di ọmọbinrin kan mu ni ọwọ rẹ, tabi o gbe e le ẹsẹ rẹ. Mo jẹ alejo si ọ patapata. Ọmọdebinrin naa si dara loju, ó rí bí ẹni pé ara rẹ́ dá. O jẹ ọmọbinrin ti o lẹwa, ti irun ori rẹ pupa. Mo n wo o bayii, ko jọ pe o yarọ tabi ohunkohun se e. Emi ko mọn ohun ti o see. O le ma se fun ọmọ naa, o lee jẹ iwọ ni o wa fun. Sugbọn mo saa rii ti iwọ joko ni ibẹyẹn pẹlu ọmọ naa, ti o si n gbadura. Mo nilati ba ọ sọrọ fun iseju kan, lati pade ẹmi rẹ gẹgẹ bi Jesu ti sọ si obinrin naa wi pe, “fun mi ni omi mu”, se o rii, lati saa ya ẹnikan sọtọ fun ayẹwo. Arakunrin Bryant ati awọn to joko si ibiyi. Mo mọn awọn eniyan wọnyi, sugbọn iwọ jẹ alejo.

Njẹ iwọ gba mi gbọ gẹgẹ bi Wolii Ọlọrun bi? Njẹ iwọ gbagbọ pe otitọ ni awọn ohun ti o gbọ lalẹ yi? Bayii, bi Ọlọrun ba fihan fun mi, ohun kan ti iwọ ti se, tabi ohun kan ti o yẹ ki iwọ ti se, tabi ohun kan ti o kuna pẹlu rẹ, tabi ifẹ ọkan rẹ kan, iwọ yoo mọn boya otitọ ni, tabi ki i se otitọ. Abi bẹẹ kọ? Bi oun ba si se iyẹn, se yoo fẹsẹ Ọrọ Rẹ mulẹ, pe o jẹ ọkan naa lana, loni ati titi lae, ati pe Ihinrere ti Luku 17:30 ni o n farahan fayeri? Iwọ gbagbọ.

89 Bayii, ki arabinrin naa, nawọ rẹ soke pe a ko mọn ara wa. Emi ko mọn ọ, sugbọn mo n gbiyanju lati wa ẹmi rẹ ri gẹgẹbi ẹni kan. Ọpọlọpọ ni o n fami. Bayii, gba eyi gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Bayii, ọmọbinrin kekere naa ni o wa fun. ko wa fun ọ, ohun to ga julọ lọkan rẹ ni ọmọbinrin kekere naa. Se iwọ gbagbọ pe Ọlọrun lee sọ ohun ti o jẹ fun mi? Iwọ gbagbọ? Se yoo ran ọ lọwọ lati gbagbọ nigba naa? O jẹ ipalara ninu ọpọlọ. Se otitọ ni? Bayii, gbe ọwọ rẹ le ori ọmọ naa, ọwọ rẹ.

90 Ọlọrun Ọwọn, Iwọ wi pe, “Amin wọnyi ni yoo maa tẹlẹ awọn ti o gbagbọ. Wọn yoo gbe ọwọ le alaisan, ara wọn yoo si da.” Obinrin naa jẹ onigbagbọ. Ọwọ rẹ wa lori ọmọ naa. Jẹ ki ara rẹ ki o da. Ni Orukọ Jesu Kristi ni mo gba adura yii. Amin.

Bayii, njẹ iwọ gbagbọ, gbogbo yin? Bi iwọ ba lee gbagbọ, ohun gbogbo lo seese. Dajudaju.

Mo mọn obinrin to joko tẹle, sugbọn oun n womi pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Emi ko ranti orukọ rẹ, sugbọn mo mọn oju obirin naa, sugbọn emi ko mọn isoro ti o ni. Iwọ gbagbọ pe Ọlọrun yoo jẹ ki nmọn isoro rẹ? Se yoo ran ọ lọwọ? Aisan itọ sugar. Bayi bi o ba jẹ otitọ ni, na ọwọ rẹ soke. Dajudaju.

O sẹlẹ pe, obinrin ti o joko ti ọ ni aisan kan naa. Alejo ni si mi. Obinrin keji yẹn ngbadura fun ẹnikan, ọmọ kan ti o yarọ. Iwọ gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ? Ọlọrun yoo see.

91 Ẹnikan lẹyin nibi yi. Ọkunrin ti o joko lọhun yẹn, ti o n gbiyanju lati sẹgun siga mimu. Se iwọ gbagbọ pe Ọlọrun yoo mu u kuro ninu rẹ? O dara. O gbagbọ bi? O lee gbaa. Emi ko ti ri ọkunrin naa ri, laye mi.

Ọkunrin kan niyii. Se o ri ojiji dudu to wa lori ọkunrin to dubulẹ le akete tabi aga yii? O nku lọ. Ikuukuu kan boo. O ni aisain jẹjẹrẹ. Emi ko mọn ọkunrin naa, n ko ri i ri . Ọlọrun mọn ohun gbogbo nipa rẹ. Otitọ niyẹn, alagba. Njẹ o gbagbọ pe Ọlọrun lee sọ ohun kan fun mi nipa rẹ? Se yoo ran ọ lọwọ lati gba iwosan rẹ? Ọrẹ rẹ kan ni o mu ọ wa sibi. Sugbọn iwọ ko wa lati ilu yii, o wa lati ibi kan ti omi pupọ wa, ti awọn eniyan ti n pẹja. Albany, Kentucky. Otitọ niyẹn. Gbagbọ, iwọ si lee pada lọ sile ni ilera pipe. Gbagbọ pe o ti ri bẹẹ. Bi iwọ ba le gbagbọ. O gbọdọ gbagbọ, ki o si gbagbọ pe a ti se e fun ọ. O gbagbọ?

92 Iwọ lati Tennessee, o ni ọmọkunrin kan ti o ni aisan asthma. Ko si nibi, sugbọn se iwọ gbagbọ pe, a o o mu larada? Nigba naa, mu asọ inuju ọwọ rẹ lọ baa. A o mu u larada, bi iwọ ba gbagbọ.

Obinrin ti o n sọkun, ti o joko ni odikeji ọmọwe Vayle ni bẹyẹn. Ojiji iku wa lori rẹ pẹlu. Emi ko tii ri obinrin naa ri laye mi. Sugbọn o ni aisan jẹjẹrẹ. Yoo ku bi a ko ba se ohun kan fun un. Njẹ iwọ gbagbọ pe Oun yoo wo ọ san bi? Arabinrin se o gbagbọ? Iwọ lee ni iwosan rẹ bi iwọ ba sa lee gbagbọ.

Obinrin kekere kan joko si ẹyin rẹ taara ti o fi asọ inuju kan bo ẹnu rẹ. Ohun pẹlu si ni aisain egbo inu. O ti ni awọn akoko kan ti o daku, ti o ko ni riran ati oyi oju. Ẹnikan lo mu ọ wa sibi. O si ni aisan obinrin pẹlu. Bi iwọ ba gbagbọ, o le pada lọ sile pẹlu ara dida.

93 Iwọ ọdọmọkunrin, o jẹ alejo si mi, iwọ ti o joko taara siwaju mi yii, ti o nwo mi. Kin ni ọ, se ara Puerto Rico tabi kin ni? (Awọn nkankan ti a ko gbọ daradara). Alejo ni mi si ọ, iwọ si mọn bẹ ẹ. Iwọ ko tilẹ wa lati orilẹ-ede yii. Sugbọn, se iwọ gbagbọ pe Ọlọrun lee fun ọ ni ifẹ ọkan rẹ? Bi mo ba sọ fun ọ ohun ti iwọ nfẹ, se iwọ yoo gba a? Iwọ nwa ibamtisimu Ẹmi Mimọ. Otitọ ni. Gba Ẹmi Mimọ, arakunrin mi.

Ọkunrin alawọ dudu kan niyii ti o joko lẹyin nibi yii, o ni ẹdun ọkan kan, eyi si jẹ fun iyawo rẹ. Obinrin na ko tilẹ si nibi. O ni wahala kan pẹlu ẹsẹ rẹ. O gbagbọ pe Ọlọrun yoo wo san? O gbagbọ? Alejo ni ọ nibi. O wa lati oke okun. O wa lati Jamaica. Njẹ o gbagbọ pe Ọlọrun lee sọ orukọ rẹ fun mi ? Ọgbẹni Braden. Se iwọ gbagbọ? Jesu Kristi jẹ ọkan na lana, loni ati titi lae.

94 Obinrin yii, ti o joko lẹyin lọhun yẹn ni ẹgbẹ iyaafin Wright, o ni ẹdun ọkan kan ninu rẹ. O n gbadura fun ọmọbinrin rẹ kan. O ti setan lati se isẹ abẹ kan. Iwọ gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan re, fun un? Oun ko ni nilo isẹ abẹ naa iwọ ba lee mu ki o gbagbọ. Emi ko lee woni san.

Ni ẹyin lọhun ninu iyara ti a ti i tọju awọn ọmọ ọwọ, mo ri Ẹmi Oluwa, tabi Angẹli Oluwa, Imọlẹ kan to nkaakiri ninu iyara itọju ọmọ ọwọ naa. O wa lori ọdọbinrin kan, oun si ni idaamu-ti-ẹmi kan to n ronu nipa rẹ. O dabi pe, o yẹ ki n mọn obinrin naa. Ọdọbinrin naa si ni wahala obinrin. Bẹẹ ni. Oruko rẹ ni iya-aafin West lati Alabama, Iya-aafin David West. Gbagbọ, Ọlọrun yo o si fifun ọ.

95 "Imọlẹ yoo wa, ati ni ọjọ naa, nigba ti a ba n fi Ọmọ eniyan han" Bi iyẹn ki i ba se, Jesu Kristi, Ọkan naa lana, loni ati titi lae, emi ko mọn ohunkohun nipa rẹ. Se o gba iyẹn gbọ bi? Ohun gbogbo lo seese fun awọn ti o gbagbọ.

Ni gbogbo ibi ti ẹrọ ibanisọrọ ati gbohun gbohun nlọ si ni gbogbo orilẹ-ede, ati ninu ile ijọsin yii, awọn melo ninu yin ni yoo na ọwọ rẹ soke, ki o si wi pe, "Onigbagbọ ni mi"? Bayii, ẹyin to wa kaarkiri nibomiran, gbogbo eniyan to wa nibi bayii ni wọn na ọwọ soke. Gbogbo ibi ti ẹ wa, o damiloju pe gbogbo yin ni o na ọwọ yin soke. Bayii di oju rẹ, mu ọwọ rẹ wa silẹ lori ẹnikan nitosi rẹ. Di wọn lọwọ mu. Gbe ọwọ re le ejika wọn. Emi gbe ọwọ mi mejeeji le awọn asọ ìnujú naa. Wo ohun ti a ti se loni. Wo ohun ti a ti se bayii.

Wọn nwo oju Mimọ Rẹ

Ti o tan pẹlu ifẹ Ọrun

Awọn alabukun, alabapin ore-ọfẹ Rẹ

Wọn ntan bi wura ninu ade Rẹ

Gbadura bayii. Ẹjẹ ki a gbadura nibi gbogbo.

96 Ọlọrun Ọwọn, wakati na ti de. Kin ni eyi tumọn si? Ọlọrun n mu Ọrọ Rẹ sẹ. Kin ni ifamọra naa, Oluwa? O jẹ Ọlọrun ti o n mu Ọrọ Rẹ sẹ. Kin ni eleyi kaakiri orilẹ-ede yii, nipasẹ ẹrọ ibanisọrọ, ti ogunlọgọ eniyan gbe ọwọ le ara wọn nibi gbogbo lati eti okun kan, de eti okun miiran, lati iha Ariwa titi lọ de Guusu, lati Ila Oorun titi lọ de Iwọ rẹ? Awọn lo joko nibi yii, lati awọn orile-ede miiran loke okun, ọpọlọpọ ipinlẹ Mexico, Canada, ti a si gbe ọwọ le ara wa. Ọlọrun n mu Ọrọ Rẹ sẹ.

Bawo ni eyi se ri bayii, ti ẹnikan yoo fi duro nihin, ki o si pe ọkunrin kan nipa Ẹmi Mimọ bi o ti se si Simoni Peteru, wi pe,"Simoni ni oruko rẹ, iwọ ni ọmọ Jona?"

"Lọ pe ọkọ rẹ wa si ibi yi"

"Emi ko ni ọkọ"

"Looto, o ti ni marun-un"

Obinrin naa wi pe, "Emi mọn pe Mesaya nbọ lati se eleyii, sugbọn ta ni Iwọ?"

O wipe, "Emi ni Mesaya naa".

97 Iwọ si jẹ ọkan naa lana, loni, ati titi lae. Iwọ si ti se ileri pe, "Isẹ ti Emi n se ni ẹyin naa yoo se pẹlu. Ju eyi lọ ni ẹyin yoo se, nitori ti Emi n lo sọdọ Baba. Si kiyesii, ni opin ọjọ, Emi yoo ran Wolii Elijah si yin, oun yoo si yi ero ọkan awọn eniyan pada, yoo yi ọkan awọn ọmọ pada si ẹkọ Bibeli ti awọn Aposteli. Imọlẹ yoo si wa ni igba asaalẹ.

Awa ni yii, Ọlọrun nla ti Ọrun. Wakati naa ti de. A ti gbe ọwọ le awọn eniyan.

Satani, a ti sẹgun rẹ. Opurọ ni ọ. Ati gẹgẹbi iransẹ Ọlọrun kan, ati gẹgẹbi awọn iransẹ, a pasẹ pe ni Orukọ Jesu Kristi, ki o gbọran si Ọrọ Ọlọrun, ki o si jade kuro ninu awọn eniyan nitori a ti kọ ọ pẹ, Ni Orukọ Mi, ni wọn yoo le ẹmi esu jade"

Ki a si tu gbogbo awọn eniyan naa silẹ. Se e fun wa, Ọlọrun Ọwọn. Iwọ ni Ọlọrun Ọrun ti o sẹgun gbogbo aisan, ati arun ati gbogbo isẹ esu ni ọjọ naa, pẹlu ifamọra ni Oke Kalfari. Iwọ ni Ọlọrun. Nipa ina Rẹ ni a si ti mu awọn eniyan naa larada. A tu wọn silẹ ni ominira. Ni Orukọ Jesu Kristi. Aamin.

98 Ọlọrun, gbogbo asọ ìnujú ti o wa nibi yii, nigbati Ẹmi Ọlọrun wa nibi, nigba ti itamin Ororo Jesu Kristi wa lori awọn eniyan, ti a si nmu awọn isẹ iyanu ti Oun seleri sẹ, ti aye si n ni ẹgbọn riri, awọn ìsẹ̀lẹ̀ naa n sẹlẹ̀, awọn isẹ amin nla ti O seleri, ati awọn Iwe Mimọ n di mimusẹ, ti imọlẹ asaalẹ si n tan. Mo gbe ara mi le awọn asọ ìnujú wọnyi gẹgẹbi asoju fun gbogbo ẹgbẹ onigbagbọ nla yii, lati Ila Oorun, Iwọ Oorun, Ariwa, ati

Guusu, mo si sọ fun esu pe, “ni Orukọ Jesu Kristi, jade kuro lara gbogbo alaisan ti a ba fi asọ yi le lara” si ọla ati Ogo ti Ọrọ Ọlọrun. Ni Orukọ Ọrọ Ọlọrun, Jesu Kristi ti Nasarẹti. Aamin.

99 Bayii, pẹlu idakẹjẹ, pẹlu ori pipe, tọwọ tọwọ, ninu ọkan ti o ye kooro, gẹgẹbi onigbagbọ, se iwọ gbagbọ bayii, ti o si gba iwosan rẹ lati ọdọ Ọlọrun Olodumare, ni Orukọ Jesu Kristi? Bi o ba se bẹẹ, na ọwọ rẹ soke. Ni gbogbo ibi ti ẹ wa lorilẹ ede, ẹ na ọwọ yin soke nibẹ. Gbogbo eniyan ti o wa nibi, bi mo se lee ri awọn eniyan to, lo nawọ wọn soke, ninu ile, ni ode, nita lọhun, ni gbogbo oju ferese, ni ẹnu ọna, ninu iyara ti a tii tọju awọn ọmọ ọwọ ati kaakiri nibi gbogbo, ni o ka ọwọ wọn soke. Wọn gba a. A ti sẹgun satani. Ina Jesu Kristi wo yin san, Iwalaaye Isọkalẹ Jesu Kristi si jẹri si otitọ naa pe, Oun wa laaye loni, ti O si ni ipa lati pa gbogbo ileri Rẹ mọn. Aamin. Mo gba A gbọ. Iwọ nkọ?

100 Bayii, ẹ jẹ ki a dide duro ni ẹsẹ wa. Ni Orukọ Jesu Kristi, a gba ohun gbogbo ti a ti se, tabi ti a sọ, a nifẹ Rẹ pẹlu gbogbo ọkan wa. A mọn riri Rẹ pẹlu gbogbo ohun ti o wa ninu wa. Ati bayii, bi ẹ ti n lọ si ile olukuluku yin, ki Ọlọrun ma a ba yin lọ. Ki Ọlọrun fun ọ ni Ẹmi Mimọ bi iwọ ko ba ti ni I.

101 Olukuluku ọkunrin, obinrin, ọmọkunrin, tabi ọmọbinrin to wa nibi, ti a ko tii se itẹbọmi ni Orukọ Jesu Kristi, asọ wa nibi, adagun omi si wa fun itẹbọmi. Mase fi ohun ti o ba lee se loni di ọla. Ọla lee pẹ ju. “Buburu ti oojọ kan to fun un” Awọn iransẹ Ọlọrun wa ni iduro, wọn si setan, asọ si wa. Ko si awawi. Se iwọ setan? Bi iwọ ba setan, gbagbọ. Bi o ti wu ki iwọ ti se itẹbọmi tẹlẹ - a wọ́n omi le ọ ni, a da omi le ọ ni, ohunkohun ti i ba a jẹ - isina ni. Imọn otitọ naa ti de. Wa, gbagbo, ki a si tẹ ọ bọmi.

102 Ati bayii, titi di agogo mẹsan abọ, owurọ ọjọ Aiku ti o nbọ, jẹ ki a kọ orin kekere yii, ti a maa n kọ ni ọpọ ọdun sẹyin.

Ma gbagbe adura ẹbi.

Jesu fẹ pade rẹ nibẹ,

Yoo gba gbogbo aniyan rẹ,

Ma gbagbe adura ẹbi,

Jẹ ki a jọ kọ papọ bayii,

Ma gbagbe adura ẹbi,

Jesu fẹ pade rẹ nibẹ,

Yoo gba gbogbo aniyan rẹ,

Ah, ma gbagbe adura ẹbi.

Bayii, bi a se n kọ ọ lẹẹkan si, bọwọ pẹlu atipo kan nitosi rẹ, se o rii, bi a se n kọọ.

Ma gbagbe adura ẹbi

Ah, Jesu fẹ pade rẹ nibẹ,

Oun yoo gba gbogbo aniyan rẹ

Ah, ma gbagbe adura ẹbi.

103 Se iwọ ko nifẹ Rẹ bi? Mo nifẹ Rẹ. Mo fẹran Rẹ nitoripe, O kọkọ fẹ mi, O si san gbese igbala mi (ohun to fa ifamọra naa niyẹn) ni Oke Kalfari. Ifamọra kan naa ni Oke Sunset, Oke Nebo, Oke Sinai, gbogbo awọn iriri ori oke tente -meje. O dara, jẹ ki a kọrin naa bayii.

Mo fẹran, Jesu yii

To ri o kọ fẹmi

O san gbese igbala mi

Ni Kalfari.

Gbogbo awọn to nifẹ Rẹ, ẹ sọ pe, “Aamin”. Bayii, saa ronu ohun ti O ti se fun ọ. Roo wi pe, iwọ iba ti wa nita, nile ọtin lalẹ yii. Oseese ki iwọ ti wa ninu iboji, bi emi iba ti se, bi ko ba si aanu Ọlọrun. Kin ni O se fun ọ? Ah, bawo ni a se le se alai-nifẹ Rẹ? Ko se pataki ohun ti ẹnikẹni lee sọ, Oun ni akọkọ.

104 Ẹ jẹ ki a di oju wa, ki a si tẹ ori wa ba, bi a se n kọrin yii si I bayii. Ó ni fẹ orin, kikọ orin mimọ. Jẹ ki a

kọrin naa si I bayii.

Mo fẹran. Jesu yii

Tori o kọ fẹ mi

O san gbese igbala mi

Ni Kalfari.

Pẹlu ori wa, ati ọkan wa ni titẹba, ni imọnriri ohun ti oju wa ti ri, ati ti eti wa ti gbọ, awọn ti a kọ silẹ sinu Ọrọ Ọlọrun, ohun ti ileri Rẹ ti jẹ fun wa loni. Ki Ọlọrun bukun yin.

105 A ni alejo kan pẹlu wa lalẹ yii, arakunrin kan, Ned Iverson, ti o jẹ oniwaasu Ijọ Pirẹsibiteria tẹlẹ. Baba rẹ, ati awọn arakunrin rẹ jẹ oniwaasu ijọ Pirẹsibiteria. Mo loye pe, o se itẹbọmi loni lẹẹkan si ni Orukọ Jesu Kristi. O jẹ Oniwaasu, eyi ti o dara gidi si ni. Bayii, emi yoo pe, lati wa gbadura fun apejọpọ yii, nitoripe mo gbagbọ pe, iransẹ Ọlọrun ni i se.

Arakunrin Iverson, wa siwaju, nigba ti a tẹrba fun adura. Ki Ọlọrun bukun ọ, arakunrin mi.

MESSAGE hub online

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info